# Jèhófà-Jírè Apá Kejì

Louisville, Mississippi, USA

Ọjọ Kẹta, Oṣu Kẹrin, 1964

1 Ẹ jẹ ki a wa ni inaro, fun iṣẹju kan, bi a o ṣe tẹriba.

Baba wa ọrun, a dupẹ ni aṣalẹ yii, fun anfaani ti a ni, lati tun wa si ile ijọsin, nibiti a ti n fi ara wa ati awọn iṣoro wa si iwaju Rẹ, nitoriti O ṣe ileri lati pade wa nibi yii labẹ Ẹjẹ naa. Ibi kanṣoṣo ti Ọlọrun pese silẹ ti ẹlẹṣẹ, tabi ẹnikẹni ti lee ba Ọlọrun pade, oun ni abẹ Ẹjẹ ti a ta silẹ. Nitorinaa, a wá ni orukọ Jesu Oluwa, bi a ti mọ wipe O ṣe ileri rẹ. Bi a ba beere ohunkohun ni Orukọ yẹn, a o fi fun wa. A gba Ọ gbọ, Baba. Ran aigbagbọ wa lọwọ. A gbadura wipe ipejọpọ wa ni aṣalẹ yii yoo wa fun ogo Ọlọrun, ki a lee fi ọla fun Ọlọrun, ki a si mọ orukọ Rẹ̀ laarin awọn eniyan. Nitoriti a beere rẹ ni Orukọ Jesu, Ọmọ Ọlọrun. Amin.

Ẹ lee joko.

2 Mo ka eyi si anfaani lati tun wa nibi ni aṣalẹ yii, ati lati ri ẹgbẹ eniyan rere ti o pejọpọ sibi yii. Mo gbagbọ wipe wọn ni ibiti wọn n ko ẹru si ni ibi yii tẹlẹ. Oniruuru ibi ni mo ti ṣe ipade kaakiri agbaye. Mo ranti ni California, mo ti ṣe ipade bii meji tabi mẹta nibẹ, ni ibikan ti wọn n pe ni Cow Palace. Ati oniruuru ìwọ̀n, lati iyara kekere kan ti o lee gba eniyan marun tabi mẹfa, titi de ọpọ ero ti a ni ti o pọ ju lẹẹkanṣoṣo, ni Bombay, ẹgbẹrun lọna ẹẹdẹgbẹta eniyan ninu ipade kanṣoṣo.

Ṣugbọn Oluwa ṣe ohun nla ni Bombay, O gba ọpọlọpọ eniyan la. Iba ṣe wipe a lee mu ki awọn ijọ ni ifọwọsowọpọ ni, wọn lee gba awọn ẹlẹsin Hindu ati bẹẹ bẹẹ lọ. Awọn yẹn ni a si n pe ni “alaigbagbọ” gan-an. Ẹnikẹni ti ko ba gbagbọ ninu Jesu Kristi Oluwa, a n pe e ni “alaigbagbọ.” Ẹgbẹẹgbẹrun awọn eniyan ni wọn si gba Kristi, ṣugbọn o lee… o ko lee de ọdọ wọn.

Ẹwẹ, ni Durban, South Africa, a ni akọsilẹ ẹgbẹrun lọna ọgbọn eniyan nibi ipe si pẹpẹ ni ọsan ọjọ kanṣoṣo. Nibiti o jẹ wipe ni ọjọ keji, alaga ilu naa, Sidney Smith, ti Durban, pẹlu awọn ọkọ Britain nla bii meje tabi mẹjọ ti o kun fun ọ̀pá arọ ati awọn nkan ti awọn eniyan fi n rin tẹlẹ, fun ọgọọgọrun maili. Ọpọlọpọ ọsẹ ni wọn fi gbe wọn wa ninu ibusun alaisan, lati ileto. Ibẹ kun fun awọn nkan wọnyẹn.

Alaga naa pe mi, o ni, “Lọ si ibi ferese rẹ ti o doju kọ Indian Ocean, ni ibi ile itura ti o wa,” o ni, “iwọ yoo si ri ohun ti o ko ri ri.”

Awọn ọkọ nla wa nibẹ, ti wọn kun fun awọn ọpa arọ ati awọn ibusun alaisan, ati bẹẹ bẹẹ lọ, ti wọ̀n fi n gbe awọn olufẹ wọn jade wa lati ileto. Awọn eniyan ti o si wa ninu awọn ibusun ni ana, n rin lẹyin ọkọ̀ naa, wọn n kọ orin Ṣaa Ti Gbagbọ ni ede tiwọn. Iran ti o dun lati wo ni.

Awọn dokita wa nibẹ. Ọpọlọpọ wọn ni o yẹ awọn alaisan naa wo, lati ri i daju wipe ara wọn da nitootọ. A ko fẹ kede ohunkohun, bẹẹni a ko fẹ kọ ohunkohun silẹ, bikoṣepe a fidi rẹ mulẹ wipe otitọ ni. A gbọdọ fidi rẹ mulẹ!

3 Mo ṣẹṣẹ ri lẹta kan gba lati… laipẹ yii ni. O ṣẹṣẹ de ọwọ mi ni. Dokita olokiki kan ni Indiana ni. Onigbagbọ ijọ Katoliiki ni. Ọmọkunrin rẹ jẹ alufaa ni ile-ẹkọ ẹsin ti St. Meinard ni Jasper, Indiana. Ẹni naa ni Dokita C. Ackerman. Mo pade rẹ lẹẹkan ri ni igbẹ ọdẹ. O ti n dọdẹ agbọnrin oniwo pupọ fun ọdun mọkanla. Ko si ri ọkankan pa. Ni alẹ ọjọ yẹn, a jọ wa papọ titi di bii agogo meji oru, a n sọrọ nipa Oluwa.

Mo gbọ wipe dokita yii wa nibi ipagọ naa. Nigbati mo de ibẹ, ireti mi ni lati ri ẹnikan ti o jẹ onigberaga ati alaibikita. Ṣugbọn ọkunrin ti mo ba pade jẹ eniyan rere, ẹni adun. O wa ba mi, o wipe, “Ṣe iwọ ni Arakunrin Branham?”

Mo ni, “Bẹẹni, sà, emi ni.”

O bọ mi lọwọ. O ni, “Emi ni Dokita Ackerman.”

Mo ni, “O dara, inu mi dun pupọ lati mọ ọ.”

A bẹrẹ si sọrọ nipa Ọlọrun, ati bi o ṣe jẹ wipe ti O ba jẹ Ọlọrun, O nilati jẹ Ọlọrun sibẹ, aijẹbẹẹ, ko fi igba kankan jẹ Ọlọrun niyẹn. Ṣe o ye yin? Ọlọrun itan ko wulo loni, ti ko ba ri bakannaa si awọn eniyan ode oni gẹgẹbi O ti ri ni igba yẹn.

Ni nkan bii agogo mẹta, a - ẹ̀ṣọ́ kan jí wa. A si… Emi naa n ṣe ẹṣọ, nitorinaa, a nilati rin irin-ajo kan, ki a ko awọn eniyan wa lọ si oniruuru ibiti a ti n ṣọ́. Loju ọna, ọdọ mi ni wọn pin Dokita Ackerman si.

Nigbati a n lọ loju ọna, o duro, nigbati o ku diẹ ki ilẹ mọ. O gbe ọwọ rẹ le ejika mi, o ni, “Arakunrin Branham?”

Mo ni, “Emi niyi, dokita.”

O ni, “Jesu Kristi da mi loju gidigidi.” O ni, “Mo ni ọmọkunrin kan, ṣe ẹ mọ, ti o jẹ alufaa ni ile-ẹkọ ẹsin ijọ Katoliiki.”

Mo ni, “O dara, sà.”

O ni, “Onigbagbọ Katoliiki ni emi. Mo lero wipe ijọ niyẹn.” O ni, “Mo gbagbọ pe ti - ti Oun ba jẹ Ọlọrun, Ọlọrun gbogbo eniyan ni.”

Mo ni, “Bẹẹ gan-an ni. Oun ni o da gbogbo eniyan. Nipa Ẹjẹ kanṣoṣo ni o fi da gbogbo orilẹ-ede.”

O wa ni, “Bẹẹni, sà, mo gba iyẹn gbọ.” O ni, “Mo ti ka awọn iwe rẹ.” O ni, “Mo ni igbẹkele yii. Mo gbagbọ wipe ti o ba beere lọwọ Ọlọrun, wipe ki O fun mi ni agbọnrin oniwo pupọ loni, emi yoo ri i pa.” O ni, “Ọdun mọkanla ni mo ti n dọdẹ rẹ; mo si ti bọ sinu igbi yinyin ri.”

Mo ni, “Emi yoo sọ fun Oluwa wipe ki O fun ọ ni ọkan, dokita. Gbogbo ohun ti mo lee ṣe niyẹn.” Nigbati mo beere lọwọ Rẹ̀, mo gbadura fun-un. Mo ni, “Dokita, ni agogo mẹsan owurọ yii, Oluwa yoo fun ọ ni - akọ agbọnrin oniwọ marun-un.”

O ni, “Mo gba a gbọ.”

Gbogbo ohun ti o nilati ṣe niyẹn. “Ti o ba gba a gbọ.”

4 Emi ati ọrẹ mi kan gun oke lọ, a n wo agogo. Ni agogo mẹsan, ibọn dun. O pa akọ agbọnrin oniwo marun-un naa. A si lọ ran-an lọwọ lati gbe e wọle.

O maa n ko awọn alaisan rẹ wa ki a gbadura fun wọn. Mo ṣẹṣẹ gba ipe kan ni bayi, wipe o ni alaisan arun jẹjẹrẹ kan, obinrin kan ti arun jẹjẹrẹ n pa ku lọ, o fẹ fi ọkọ̀ ofuurufu gbe e wa sihin yii. Ṣugbọn emi n lọ si ile ni ọla, tabi ni ọtunla. Nitorinaa, mo sọ fun-un wipe ki o duro titi di igba ti a o de ibẹ, a o gbadura fun obinrin naa nigbati a ba de ibẹ.

Nitorinaa, ẹ ri i, ti a ba lee fi ọgbọn gbe ọrọ naa kalẹ fun ẹnikan! Iwosan atọrunwa ti di ohun ti a n sọrọ pupọ nipa rẹ, ọpọlọpọ gbawere-mẹsin ni o si ti wọ inu rẹ̀, gẹgẹbi o ti ri ninu ohun gbogbo. Ninu gbogbo ẹsin tabi ohunkohun, a maa n ri gbawere-mẹsin nibẹ.

Laarin awọn ẹlẹsin Mohammẹd paapaa, a ri i wipe o wa nibẹ, ati awọn ẹlẹsin Hindu pẹlu. Ẹ o ri ẹnikan nibẹ, ti o jẹ alagabagebe, ti o n pidan fun awọn arinrinajo, yoo duro lori eekannaa tabi igo, tabi iru nkan bẹẹ. Ṣugbọn ni inu lọhun, ẹni naa gbagbọ ninu nkan yẹn nitootọ. O kan n ṣe iyẹn fun irubọ ni.

A maa n ri iyẹn ninu ohun gbogbo. A maa n ri gbawere-mẹsin. Alakatakiti ounjẹ paapaa maa n jẹ ounjẹ ajẹju. Tabi ohunkohun!

Ṣugbọn ti a ba fi ọrọ naa han ninu Iwe Mimọ, a jẹ wipe ko si ohun kan ti o lee… Mo ri ọpọlọpọ awọn dokita ti wọn gbagbọ ju awọn oniwaasu lọ. Mo ri wọn. Mo ri wọn nitootọ. Ọpọlọpọ wọn ni o gbagbọ.

Wọn ti fi ọrọ wa mi lẹnu wo ni ile iwosan Mayo. Gbogbo yin ni ẹ mọ, o wa ninu awọn iwe-iroyin, ati ohun gbogbo. Ati awọn dokita awọn ile-iwosan kaakiri. Ko si nkankan. Wọn gba a gbọ. Mo - mo ti gbọ ti awọn dokita wa sọ fun mi ri, gẹgẹbi ifọrọwanilẹnuwo ti o ṣẹlẹ nibẹyẹn, wọn ni, “Awa ko sọ wipe a jẹ Oluwosan. A kan n ran ẹda lọwọ ni. Oluwosan kanṣoṣo ni o wa; iyẹn ni Ọlọrun.”

5 Ẹni melo ni o ti ka iwe Reader's Digest, nipa Donny Morton kekere yẹn, ẹniti wọn fi ọwọ si iwe wipe a ti “mu u lara da.”? Ati, “Iṣẹ-iyanu Donny Morton,” ninu iwe Reader's Digest. Wọn fi ọrọ wa mi lẹnu wo lori iyẹn. Ile-iwosan Mayo ati Hopkin ti pa ọmọdekunrin yẹn ti, ati gbogbo wọn pẹlu. Jesu Oluwa si wo o san, O mu u lara da.

Florence Nightingale, ọmọ-ọmọ-ọmọ Florence Nightingale ti o ti di oloogbe, ni London, England. Wọn gbe e wa lati Durban, South Africa.

Wọn si ti ṣi ọrọ naa gbe kalẹ. Gẹgẹbi… ni ọpọlọpọ igba ni…

Wọn ti ṣi ẹsin Kristẹni gbe kalẹ fun awọn eniyan. Wọn ti ṣi ẹsin Kristẹni gbe kalẹ fun awọn eniyan gẹgẹbi ijẹwọ igbagbọ lasan. Ẹsin Kristẹni jẹ Ẹnikan ti o wa laaye, Jesu Kristi, ti o jinde, Ọlọrun ti o wa laaye laarin wa nisisiyi. Ẹnikan ni ẹsin Kristẹni, kii ṣe ijẹwọ igbagbọ kan. “Iye ni lati mọ ọ.” Kii ṣe mimọ Ọrọ Rẹ; iyẹn ko ni Iye. “Mọ Oun,” Oun si ni Ọrọ naa.

Ọkunrin kan sọ fun mi laipẹ yii, o ni… Mo n sọrọ nipa ohun ti a ro nipa ẹsẹ Iwe Mimọ kan ninu Bibeli. Ọmọwe kan si ni ọkunrin yii. O ni, “Ko buru, o ko mọ Bibeli rẹ.”

Mo ni, "Mo mọ Ẹniti o kọ ọ daradara." Ohun ti o ṣe koko niyẹn, ti mo ba ṣaa ti mọ Oun. Oun yoo yanju eyiti o ku. "Iye ni lati mọ ọ."

6 Ni owurọ ọla, ninu ile-ijọsin nihin, agbẹnusọ mi fun awujọ, Ọmọwe Lee Vayle, yoo wa nibi. Ti awọn ibeere ba wa ni ọkan yin, ẹ wa, yoo dahun wọn, yoo ṣe ohunkohun ti o ba lee ṣe lati ran yin lọwọ. Ọmọwe Vayle wa nihin. Mo gbagbọ wipe o wa ninu ile yii, lẹyin nibikan bayi. Ọmọwe ti o dara ni, ẹniti a kọ daradara fun iṣẹ naa ni. Nitorinaa, bi ẹnikẹni ba ni ibeere kan tabi ohunkohun, dipo ki ẹ maa beere rẹ bayi, ninu ipade ita-gbangba bi eyi, ẹ kuku ri Ọmọwe Vayle. Inu rẹ yoo dun lati sọrọ nipa ohunkohun - eyiti ẹ ba fẹ ba a sọ. Yoo ṣe isin nihin ni owurọ. Inu wa yoo dun lati - lati ri awọn eniyan nihin.

Ile-ẹko Ọjọ Isimi yoo wa kaakiri ilu yii ni owurọ ọjọ Sunday. A ki - ki yoo gbiyanju lati gba ọjọ Sunday, owurọ ọjọ Sunday ati ọsan ọjọ Sunday ninu gbọngan ti a wa bayi, nitoriti - ko tọ.

Ṣe ẹ mọ, awọn ijọ, inu ijọ yin ni ojuṣe yin wa - ninu ijọ yin. Nigbati ijọ ba si n ṣe isin, ibẹyẹn - ibiti ẹ nilati wa niyẹn. A ko fẹ ki ẹnikẹni jade wa, nigbati ẹ ni ibi ti ẹ nilati wa. Bi ijọ rẹ ba n ṣe isọji, ti a si wa si ilu ti ẹ ti n ṣe isọji naa, a ko fẹ lati ṣe bẹẹ, rara. A wa ninu idapọ Kristẹni nibi, pẹlu ifarada, ati inu rere si gbogbo eniyan, ani gbogbo ijọ. Awa ko…

Emi ko si ninu ẹgbẹ ijọ ẹlẹkọ-adamọ kankan rara. Emi ko darapọ mọ ijọ ẹlẹkọ-adamọ kankan. Mo ṣaa jẹ Kristẹni ni. Ipa ti mo si ni, mo n gbiyanju lati lo o - lati bu ọla fun Kristi, ati lati mu awọn ẹlẹṣẹ wa si ironupiwada. Gbogbo ohun ti mo mọ lati ṣe niyẹn. Pẹlu ireti wipe ni Ọjọ naa, mo gbagbọ wipe yoo sọ pe, "O ku iṣẹ." Ọrọ ti mo fẹ sọ niyẹn… ti mo fẹ gbọ ki O sọ niyẹn.

Mo ti maa n ronu. Mo fẹ lati gbọ, nigbati O ba duro, ti O si na ọwọ Rẹ ni ọjọ yẹn, ki O wipe, "Ẹ wa si ọdọ Mi, gbogbo ẹyin ti n ṣiṣẹ ti a si di ẹru wuwo le lori." Iyẹn ti kọja. Ṣugbọn, "Ku iṣẹ, ọmọ-ọdọ Mi rere," yoo jẹ ọjọ iwaju. Mo n gbe igbe-aye mi ki n le gbọ ki a sọ ọrọ yẹn.

7 Ni ọsan ọjọ Sunday, a o gbadura fun awọn alaisan. Nigbamiran, awọn eniyan maa n pe iyẹn ni isin iwosan. Kii ṣe isin iwosan. Adura fun awọn alaisan ni. Ṣe o ye yin? A maa n gbadura fun awọn alaisan. Ni ọpọ igba, akoko ti nkan naa maa n ṣẹlẹ niyẹn, nigbati a ba gbadura fun awọn alaisan.

Mo fẹ ki olukuluku oniwaasu kaakiri ilu yii, ati ayika rẹ, awọn ti wọn gbagbọ, ki wọn wá, ki wọn ri i daju wipe wọn wá ni ọsan ọjọ Sunday, ki wọn duro ti wa bi a ṣe n gbadura fun awọn alaisan. Ijọ yoowu ti o jẹ tirẹ, tabi ohunkohun yoowu ti o jẹ, a ko bikita nipa iyẹn. Dajudaju, ẹ ni imọlara fun awọn eniyan yin, ati fun awọn eniyan Ọlọrun, ati awọn eniyan ti wọn n fẹ iwosan.

Ẹ ranti, nigbati aisan ba n ṣe ọ, ojuṣe rẹ akọkọ ni ki o ri dokita rẹ, ki o si gbọ ohun ti yoo sọ. Ti o ba si ri aisan kan ti o jẹ wipe - ti oun ko lee tọju; ti imọ-ijinlẹ ko lee fi han-an lati ran ọ lọwọ, nigbanaa, o ni ẹtọ lati wa sọdọ Ọlọrun. Oun ni Oluwosan nla naa. Lẹyinnaa…

Iwọ gbadura, ki o si jẹ ki a gbadura fun ọ pẹlu. Wọn maa n ṣe e, o si yẹ ki wọn maa ṣe e, ni gbogbo ijọ Kristẹni. Boya wọn n ṣe bẹẹ nibi naa. Emi ko mọ. Ṣugbọn ni ibi pupọ, awọn Kristẹni maa n gbadura fun awọn alaisan wọn. Ijọ Alagba ati ọpọlọpọ wọn n ni ipolongo ipade iwosan kaakiri iha ariwa, ati oniruuru ibi ni orilẹ-ede yii, wọn n gbadura fun awọn alaisan, wọn si n ni aṣeyọri gidigidi; ijọ Alagba, ijọ Luther, ijọ Eleto, ati ọpọlọpọ wọn.

Isọji nla wọn bẹrẹ pẹlu isin iwosan. Ṣugbọn wọn kuro ninu rẹ. Awọn ẹgbẹ titun ti o wọle wá, wọn jẹ awọn eniyan ti wọn ko ara wọn jọ, wọn si pin-in bi wọn ṣe fẹ, nipa bayi, wọn kuro ninu Rẹ, ṣe ẹ ri i, wọn tun pada sinu ẹkọkẹkọ, bii ti awọn Farisi ati Sadusi ni igba Jesu Oluwa.

Ṣugbọn bayi, gbogbo oniwaasu ni a pe, ni ọsan ọjọ Sunday, lati wa duro ti mi, ki - ki wọn si ran mi lọwọ bi a ṣe n gbadura fun awọn alaisan. Ẹ mu awọn alaisan yin wa pẹlu, ati awọn ti a n pọn loju.

A n gbiyanju bayi lati wa awọn ẹlẹṣẹ ri, awọn ti ko mọ Oluwa wa, awọn ti ko mọ wipe Oun kò kú. O wa laaye. Oun, Oun ko ku. O wa laye titi lae. O si wipe, "Nitoriti mo wa laaye, ẹyin naa yoo wa laaye pẹlu." Ileri nla ni, itunu nla si ni pẹlu, nigbati a ri i wipe akoko naa ti sunmọ tosi!

Gbogbo Kristẹni tootọ ni o gbagbọ wipe Ipadabọ Kristi lẹẹkeji ti sunmọ tosi. Bawo ni o ṣe jinna to, a ko mọ. Njẹ ẹ ri i wipe Alaska tun ni ilẹ riri bii melo kan si i loni? Ọkan ninu wọn le bii ti akọkọ, kiki wipe ko wo o palẹ ni. Ṣe ẹ mọ, Jesu wipe iru awọn nkan beyẹn yoo ṣẹlẹ ti o ba ku diẹ ki Oun de.

Ẹ si ranti, awọn ohun ti ẹ n ri ti o n ṣẹlẹ nibi yii, Ọrọ naa ti sọtẹlẹ wipe wọn yoo ṣẹlẹ, gẹgẹbi O ṣe sọtẹlẹ nipa awọn ilẹ riri naa. Nitorinaa, lapapọ, kini ṣe ti a ko lee pa ọkan wa papọ sọkan, ki a si fi sinu Ọrọ Ọlọrun, ki a si fi gbogbo ọkan wa gbagbọ? O dara.

Ni alẹ ana, a… Mo mu akori kan nipa Abrahamu, nigbati o pe orukọ Oluwa ti O farahan fun-un loke ibiti o

ti fi ọmọkunrin rẹ rubọ, nibi ti o n lọ. O pe orukọ rẹ ni Jehofa-jire, eyiti o tumọ si, "Oluwa yoo pese ẹbọ fun ara Rẹ."

8 Mo ni awọn ẹsẹ Iwe Mimọ melo kan, ati iwe kan tabi meji ti mo kọ silẹ, eyiti mo fẹ fi silẹ fun yin. Ki a to ṣe iyẹn, ẹ jẹ ki a gbadura lẹẹkan si i. Baba, a gbadura wipe ki O mu Ọrọ Rẹ… Otitọ ni Ọrọ Rẹ, Bibeli si wipe … Jesu n sọrọ, O ni Ọrọ naa jẹ irugbin ti afurugbin kan gbin. A mọ wipe ti irugbin naa ba jẹ irugbin rere, yoo hu. Ti irugbin naa ba jẹ … ṣe (ohun ti o yẹ ki o ṣe ninu ifẹ Ọlọrun), yoo jẹ irugbin ti yoo hu. Nigbati Jesu wa lori ilẹ aye, Oun ni ajara naa, irugbin ti O gbin ni Ọrọ Rẹ. A si mọ wipe o hu nipa iye Rẹ.

9 A mọ wipe nigbati irugbin ba bọ sinu ilẹ rere - kii ṣe ori apata, laini gbongbo, tabi laarin ẹgun oun oṣuṣu ti yoo fun-un pa; ṣugbọn sinu ilẹ rere, ilẹ ọlọra igbagbọ - gbogbo irugbin ni yoo so eso iru tirẹ. A si mọ wipe gbogbo irugbin, tabi ileri Ọlọrun, yoo so eso iru tirẹ - ileri ti o ṣe niyẹn - ti o ba bọ sinu ilẹ rere: ilẹ ti a ti pese silẹ, ti o ti mura silẹ, a ti sa gbogbo okuta kuro, ati gbogbo gbongbo ikoro, ati imọ-tara-ẹni-nikan, aibikita ati owú - a ti wu gbogbo rẹ kuro. Gbongbo ikoro ti o maa n hu jade, ti o si maa n ba ohun ti Ọlọrun fẹ ṣe jẹ nigbamiran, a gbadura, Ọlọrun, wipe iyẹn ki yoo si ni aarin wa; ṣugbọn ki Ọrọ rere naa lee ri ilẹ rere.

Awọn wọnyi, bi a ṣe n tẹle baba nla yii, Abrahamu, ninu ẹkọ aṣalẹ oni, jẹ ki a ri ipo wa - bi a ti mọ wipe a jẹ ọmọ Abrahamu nipa igbagbọ ninu Kristi. Ki O gba ogo fun orukọ ati ọla Rẹ, nitoriti a beere rẹ ni orukọ Jesu Kristi. Amin.

10 A o ṣe ayẹwo pada ṣẹyin diẹ ni aṣalẹ yii lori ohun ti a sọrọ le ni alẹ ana. Iyẹn ni wipe a ri Abrahamu, bẹrẹ lati Gẹnẹsisi ori kejila … ori kọkanla gan-an ni a ti sọrọ orukọ rẹ, nigbati baba rẹ sọkalẹ wa lati Babiloni, ti wọn si n gbe ni … Uri, ni ilẹ awọn ara Kaldea. A ri i pẹlu wipe Ọlọrun pe Abrahamu, eniyan lasan kan ni, ti o n jẹ Abramu. Koi tii di Abrahamu nigbanaa, Sarai ko si tii di Sarah nigbanaa. A ri i wipe Sarai ati Sarah jẹ orukọ meji ọtọọtọ, Abramu ati Abrahamu jẹ orukọ meji ọtọọtọ pẹlu.

11 A ri i nibi yii wipe a mu u de ibi ifidimulẹ ni alẹ ana, wipe Ọlọrun fidi majẹmu naa mulẹ fun-un - bi yoo ṣe fidi rẹ mulẹ fun Abrahamu wipe Oun yoo mu ileri Oun ṣẹ. A ri iyẹn ni ori kẹẹdogun iwe Gẹnẹsisi.

Ati bi … a pe Abrahamu jade ni ọwọ irọlẹ, lati pa ẹgbọrọ maaluu kan, tabi abo maaluu kan, ati abo ewurẹ kan, ati agbo kan. A de ibẹyẹn ni alẹ ana, bi o ṣe jẹ abo meji ati akọ kan, pẹlu adaba meji (tabi ẹyẹle kan ati adaba kan, ti wọn jẹ ẹbi kannaa), a si ri afiwe iyẹn - wipe iyẹn duro fun iwosan, ko si yipada rara. Iwosan n wa nipa igbagbọ nigbagbogbo. Ṣugbọn etutu naa, a mu u kuro lati inu ẹmi ẹranko si ẹmi eniyan.

Ni Majẹmu Laelae, nigbati olujọsin ba wa pẹlu ẹjẹ… Abẹ ẹjẹ ti a ta silẹ nikan ni Ọlọrun ti maa n ba eniyan pade - ibi kanṣoṣo ti O ti maa n ṣe bẹẹ, ti yoo si maa ṣe bẹẹ. Ki yoo ba ọ pade labẹ ẹkọ adamọ rẹ. Ki yoo ba ọ pade pẹlu iwe kika rẹ. Abẹ ẹjẹ nikan ni yoo ti ba ọ pade. Ibẹyẹn nikan ni. Abẹ ẹjẹ ni gbogbo Israẹli ti maa n jọsin.

12 A tun ri i nibẹyẹn, kini a ri nibẹ, ninu itan, nipa … bi awọn eniyan ṣe maa n ba ara wọn da majẹmu. A ri i wipe ni awọn orilẹ-ede Aaringbungbun Agbaye, ati orisirisi ọna ti wọn n gba dá majẹmu; bi awa ṣe maa n ṣe loni nipa bibọ ọwọ, ati bẹẹ bẹẹ lọ, ti a o wipe, "A ti fi edidi di i"; awọn Japan maa n wọ́n iyọ si ara wọn lara fun majẹmu.

Nipa ririn irin-ajo kaakiri agbaye, a ri i wipe ọpọlọpọ awọn eniyan inu aye ṣì wà ninu ipo kannaa, eyiti wọn wa ninu rẹ ni igba atijọ, paapaa julọ ni awọn orilẹ-ede Aaringbungbun Agbaye ati awọn orilẹ-ede Ila-oorun Agbaye. Bibeli rẹ yoo di iwe titun ti o ba lọ si Ila-oorun, o ki yoo… Ni Jerusalẹmu, Palẹstini, ni ibẹyẹn, iwọ yoo… A kọ Bibeli ni… Oyinbo ni awa nibi, awọn ara Iwọ-oorun ti wọn n gbiyanju lati loye iwe Oyinbo. Ohun ti o le ni. Ti o ba lọ si ibẹyẹn, ẹ o ri i wipe igbeyawo wọn ati ohun gbogbo ṣì n ṣẹlẹ gẹgẹbi o ṣe ri ni igba Kristi. Ọpọlọpọ nkan ni koi tii yipada nibẹ, nipa ọna ti wọn n gba ṣe nkan, ati awọn àṣà wọn.

13 Ni bayi, a ri i ninu eyi wipe, nigbati wọn ba fẹ ṣe majẹmu ni igba atijọ, wọn yoo kọ ọ sinu iwe-awọ, awọ ni. Wọn yoo si pa ẹranko kan, wọn yoo duro si aarin ẹla ẹranko naa, wọn yoo ya a - majẹmu wọn - si meji (iyẹn ọrọ wọn), wọn yoo ya a si meji beyẹn. Nigbati wọn ba pade, eyi nilati ba iyẹn mu bakannaa, o nilati ri bakannaa - o nilati ba ara wọn mu, nitorinaa, a ko lee ṣe ẹ̀dà rẹ̀.

Nitorinaa, a ri i ninu ẹkọ wa ni alẹ ana, a ri i wipe … ohun ti Ọlọrun ṣe lati fidi majẹmu Rẹ mulẹ fun Abrahamu.

14 Ni bayi, Abrahamu - a ṣe ileri naa fun Abrahamu ati iru-ọmọ rẹ lẹyin rẹ; kii ṣe fun Abrahamu nikan, ṣugbọn fun iru-ọmọ rẹ. Iru-ọmọ naa, iru-ọmọ ti ara Abrahamu ni Isaaki; ṣugbọn iru-ọmọ ẹmi fun igbagbọ Abrahamu ni Kristi. Kii ṣe nipasẹ Isaaki ni a o ti bukun fun gbogbo aye; ṣugbọn nipasẹ Kristi, iru-ọmọ alade naa, ni a ti bukun fun gbogbo aye. Nitori gbogbo eniyan ni O ku fun - gbogbo orilẹ-ede, ati gbogbo eniyan.

15 A tun ri i ninu eyi, ninu majẹmu yii, wipe O fi ohun ti Oun yoo ṣe han nibẹ: bi Ọlọrun yoo ṣe fa Kristi Jesu

ya si meji; a gbe ara Rẹ lọ soke, o si wa ni ọwọ ọtun Ọlanla Ọlọrun ni oke; a si mu Ẹmi Kristi sọkalẹ wa sori ilẹ aye.

Ti a ba ni akoko, a lee fidi rẹ mulẹ wipe ohunkohun ti Iwe Mimọ ba sọ nibikan, o wa ninu gbogbo Bibeli. Ti ko ba ri bẹẹ, a jẹ wipe nkankan ti kuna. Majẹmu Laelae jẹ ojiji Majẹmu Titun, ojiji rẹ ni. Ti o ba si ri ojiji, o lee sọ ohun ti Titun yoo jẹ. Ibi ti O wà niyẹn, ti yoo si wà.

16 Ẹmi Kristi yii pada sinu ijọ; iyẹn ni o si mu Johanu 15 ṣẹ, nibiti O ti wipe, “Emi ni ajara; ẹyin si ni ẹka.” Ẹwẹ, ni Johanu 14:12, “Ẹniti o ba gba mi gbọ, iṣẹ ti mo ṣe ni oun naa yoo ṣe pẹlu.” Iṣẹ kannaa, nkan kannaa ninu gbogbo Iwe Mimọ. “Bi ẹyin ba n gbe inu mi, ti ọrọ mi si n gbe inu yin, ẹ o beere ohun ti ẹ fẹ, a o si ṣe e fun yin.” Ọpọ awọn nkan ti Kristi… “Ni igba diẹ si i, aye ki yoo ri mi mọ, [”aye“ ni ibẹyẹn, ede Giriki ni ”cosmos,“ eyiti o tumọ si ilana aye ki yoo ri mi mọ]; ṣugbọn ẹyin yoo ri mi, nitori Emi [”Emi“ jẹ ọrọ arọpo-orukọ ẹnikan], emi yoo wa pẹlu yin, ani ninu yin titi de opin aye,” eyiti o mu ki Jesu Kristi jẹ ọkannaa lana, loni, ati titi lae.

O wa bakannaa. O jinde kuro ninu oku. “Aye [alaigbagbọ] ki yoo ri mi.” Wọn ki yoo da a mọ, ṣugbọn awọn onigbagbọ yoo da a mọ, nitori Jesu kannaa ti o jẹ tẹlẹ ni o jẹ nigbagbogbo. Ko yipada ri - ọkannaa ni lana, loni, ati titi lae.

17 Emi si ni… Ọrọ yẹn, ọpọlọpọ ni o n mu ki o dabi ẹni wipe ko ni imisi.

Mo fẹ sọ nkankan nibi yii bayi. O ṣẹṣẹ wa si ọkan mi ni…

18 Emi ko gbagbọ wipe pẹpẹ iwaasu wa fun awada. Ibi yii kii ṣe ibi awada. Otitọ ọkan ni eyi. Bi a ti ri i wipe ọjọ Oluwa n sunmọ tosi, o yẹ ki a jẹ olootọ si i. Ṣugbọn wọn sọ itan odọmọkunrin kan fun mi ni igba kan. Eyi ṣẹlẹ ni Boston. O lọ. O ni iya rere (lakọkọ, lati bẹrẹ itan naa), iya naa si mọ wipe ọmọ oun ni ìpè ninu aye rẹ lati sin Oluwa. Iyẹn yoo ran gbogbo iya lọwọ. Fun iya tootọ kan lati mọ wipe ọmọ oun … wipe Ọlọrun bu ọla fun oun pẹlu ọmọ ti yoo waasu ihinrere - iyẹn yẹ ki o jẹ ogún fun aye eyikeyi iya. Nitorinaa, iya yii n gbiyanju lati ṣe gbogbo ohun ti o lee ṣe, o ran-an lọ si ile-iwe, si ile-ẹkọ ẹsin kan lati gba oyè akọkọ.

19 Nigbati o lọ, aisan ṣe iya rẹ gidigidi. Oun si niyi, gẹgẹbi eyikeyi Kristẹni tootọ yoo ti ṣe, wọn pe dokita. Dokita naa … o ni ilọpo meji otutu aya, dokita naa si sa gbogbo ipa rẹ lati da otutu aya naa duro; ko si nkankan. O fun-un ni oogun - oriṣiriṣi oogun - lati pa kokoro aisan naa. Ko si eyiti o ṣiṣẹ nibẹ. Aisan iya naa n le si i ni.

Nitorinaa, wọn ranṣẹ si ọmọ rẹ - ẹniti o wa ni Asbury, Kentucky, ni ile-ẹkọ giga Wilmore College - wipe ki o wa wo o, nitoriti o ti fẹ ku. Ni owurọ ọjọ keji, nigbati ọmọkunrin naa n mura ati kuro, o gba iwe pajawiri kan wipe: Ara iya rẹ ti ya daradara. Duro de igba ti a o tun pe ọ.“

20 Lẹyin bii ọdun kan, iya yii ni anfaani lati ri ọmọkunrin rẹ. O wa si ile fun isimi, nigbati ko si ile-iwe. O si wipe, “Mama, mo gbọ wipe ara rẹ ya,” lẹyin ti wọn ti jọ sọrọ diẹ, gẹgẹbi ọmọ ati iya ti maa n ṣe. O ni, “Emi ko mọ iru oogun ti dokita yẹn yipada, eyiti o mu ki ara rẹ tete ya bẹẹ.”

O ni, “Ọmọ, kii ṣe bẹẹ.” O ni, “Ṣe o mọ ibi ti ijọ kekere kan wa ni isalẹ ibẹyẹn? Awọn eniyan ti o wa ni isalẹ ibẹyẹn, ti…”

O ni, “Bẹẹni, mo ranti iyẹn.”

O ni, “Obinrin kan wà ti o sọ wipe a dari oun lati wá sihin yii, ki oun beere lọwọ mi boya olusọ-aguntan lee wa gbadura fun mi. Mo si sọ fun-un wipe o dara, nitorinaa…” O ni, “Olusọ-aguntan naa wá, o si ka a jade ninu Bibeli, wipe, 'Bi ẹnikẹni ninu yin ba n ṣaisan, ki o pe awọn alagba, ki wọn ta ororo si i, ki wọn si gbadura fun-un. Adura igbagbọ yoo gba alaisan naa la.'” O ni, “Ṣe o mọ, o ka iyẹn jade lati inu Iwe Mimọ. O gbadura fun mi, o ta ororo si mi ni ori. Ni owurọ ọjọ keji, ara mi ya tobẹẹ ti dokita fi aaye gba mi lati joko, laarin ọjọ melo kan, ara mi ti ya.”

O ni, “Ko buru,”…

O ni, “Ah, ẹ yin Oluwa.” O ni, “Ọmọ, o yẹ ki o…”

21 O ni, “Mama, iwọ naa ti n ṣe bi awọn eniyan wọnyẹn.” O ni, “Feti silẹ, iya mi.” O ni, “Wọn ti kọ wa ni ile-iwe wipe ibi ti o ka yẹn, ẹsẹ Iwe Mimọ keji ti o ka ni Marku 16, nibiti o ti wipe, 'Ami wọnyi ni yoo maa ba awọn ti o gbagbọ lọ. Wọn yoo gbe ọwọ le alaisan, ara wọn yoo si dá.'” O ni, “Wọn kọ wa ni ile-iwe wipe Marku 16, lati ẹsẹ ikẹsan wa si isalẹ, kò ní imisi.” O ni, “Ṣe o mọ, awọn eniyan wọnyẹn ko lọ si ile-iwe. Ọpọlọpọ awọn ti o wa nibẹyẹn ko kawe - alaimọkan eniyan ni wọn.” O ni, “Ko si iyemeji wipe wọn ni erongba ti o dara, ṣugbọn,” o ni, “a ti kọ wa ni ile-iwe wipe lati ẹsẹ ikẹsan wa si isalẹ, wọn kan fi iyẹn kun-un ni, boya lati ọwọ Vatican tabi nkankan. Ṣugbọn,” o ni, “nitori … a kò mí si apa ibẹyẹn.”

Mama naa si pariwo “Halleluya!” nla.

Nitorinaa, o wipe, “Mama! O dara, kini idi ti o fi sọ bẹyẹn?”

O ni, “Mo kan n ronu ni, ọmọ mi. Ti Ọlọrun ba lee wo mi san pẹlu Ọrọ ti ko ni imisi, kini yoo wa ṣe pẹlu eyiti o ni imisi?”

22 Bii awọn ileri miiran: “Ẹ beere ohunkohun ni orukọ mi, emi yoo ṣe e.” “Bi ẹ ba wi fun oke yii pe ṣidi, ti ẹ ko si ṣiyemeji ninu ọkan yin, ṣugbọn ti ẹ gbagbọ wipe ohun ti ẹ sọ yoo ṣe, ẹ o ri ohun ti ẹ beere gba.” “Nigbati ẹ ba n gbadura, ẹ gbagbọ wipe ẹ ti ri ohun ti ẹ n beere gba, a o si fi fun yin.” Ṣe e ri i, gbogbo rẹ ni o ni imisi, gbogbo rẹ pata!

23 Nigbati Morris Reedhead, ọmọwe kan ti o dara, ti o wa si ile mi, o gba baptisiimu Ẹmi Mimọ, o ṣubu le tabili kekere kan ninu ile. O sọ fun mi, o ni, “Arakunrin Branham, mo gbọ wipe iwọ jẹ … ọmọ ijọ Onitẹbọmi.”

Mo ni, “O dara, a kan gbe ọwọ le mi ni ijọ Missionary Baptist Church nigbati mo ṣì jẹ ọmọdekunrin ni. Emi kii ṣe ara…”

O ni, “O dara, awọn wo tun ni awọn ijọ Afede-ajeji-sẹri-Ẹmi-Mimọ ti o n ba to pọ yii?”

Mo ni, “Eniyan bii temi ati tirẹ ni wọn.”

O ni, “O dara, feti silẹ,” o ni, “Ṣe o ro wipe Ẹmi Mimọ ni ohun ti wọn ni yẹn?”

Mo ni, “Dajudaju.”

O ni, “Eeṣe ti wọn fi n tàpá, ti wọn n jan ẹsẹ mọlẹ, ti wọn si n pariwo?”

Mo ni, “Ko buru, wọn nilati fi ohun ti o wa ninu wọn han, lati lee mu ki o ṣiṣẹ.” Mo ni, “Ti o ba lee jẹ ki wọn mọ ohun ti o jẹ… Dipo ki ẹ fi si ibikan, ẹ nilati jẹ ki o ṣiṣẹ! Igbagbọ niyẹn, loju popo, wọn n gbiyanju lati mu awọn eniyan wọle - sinu ijọba Ọlọrun.”

24 O si wipe, “Ko buru, mo ti ri i ti wọn n ṣe bẹyẹn, nitorinaa, mo fẹ sọ ohun ti o gbe mi wa sihin fun ọ.” O ni, “Ọmọ rere kan lati India…” O ni, “O ti kawe ni ile-iwe.” O ni, “Mo… Nigbati mo fẹ kuro, mo mu u lọ sibi ọkọ ofuurufu, lati fi sinu ọkọ ofuurufu, ki o lee pada lọ si oke okun, mo sọ fun-un, mo ni, 'Ọmọ, o ti ka iwe bayi, o n pada lọ sọdọ awọn eniyan rẹ.'” Mo ro wipe iwe ti o ka ni, emi ko ro… mo ro wipe ẹkọ nipa ina manamana ni.

O ni nigbati o n pada lọ, o ni. “Kini ṣe ti o ko gbagbe wolii yin ti o ti ku yẹn, Mohammed, ki o si gba Jesu Kristi ti o jinde sinu ọkan rẹ?”

O sọ pe, “Alagba, mo fẹ beere ohun kan lọwọ rẹ.”

25 (Ẹ ranti, eyi wá lati ọkan ninu awọn ile-ẹkọ Bibeli ti o ga julọ, awọn ti n kọni ni ẹkọ gan-an. Ọkunrin yii jẹ ọkan ninu awọn olukọ wọn.) O ni, “Kini Jesu rẹ lee ṣe fun mi, ju ohun ti wolii temi lee ṣe?”

O ni, “O dara,” o ni, “Jesu mi lee fun ọ ni iye ainipẹkun.”

O ni, “Temi … Kurani mi ṣe ileri kannaa.” (Kurani ni bibeli awọn Musulumi.) O ni, “O ṣe ileri kannaa.”

O ni, “O dara,” o ni, “Bẹẹni, mo…”

O ni, “Njẹ o mọ, Kurani ko ṣe ileri kankan … Mohammed ko ṣe ileri kankan bikoṣe iye lẹyin iku.” O ni, “Jesu ṣe ileri fun ẹyin olukọ wipe iṣẹ-ami ati iṣẹ-iyanu wọnyi ni yoo maa tẹle yin.” O ni, “Ohun ti Jesu sọ niyẹn.” O si wipe, “A fẹ ri ki ẹ ṣe iyẹn, ki ẹyin olukọ ṣe nkan yẹn.”

Ẹ ronu nipa rẹ.

26 O sọ fun mi pe, “Lojukannaa,” o ni “mo mọ wipe ẹniti mo ba pade kii ṣe majesin. Mo mọ wipe ẹniti o mọ ohun ti o n sọ ni.” (O ṣee ṣe ki o ti maa sere, ṣugbọn ọna kan ti o dara lati gba ṣe e niyẹn. Jẹ ki ọta doju ko ọ lẹẹkan bi iyẹn, iwọ ki yoo si mọ ibi ti o lee lọ, ṣe ẹ ri i.) Nitorinaa, o wipe, “Mo mọ wipe kii ṣe majesin niyẹn.”

O tun ni … o ni, “O dara, wo o bayi. Jesu jinde kuro ninu oku.”

O ni, “Ṣe Ó jinde?” O ni, “Ẹ ni ẹgbẹrun ọdun meji lati fidi rẹ mulẹ, ko si fẹrẹ jẹ wipe … idameji ninu idamẹta aye ko gbọ nipa Rẹ. Kini o n ṣe ẹyin eniyan wọnyi?” O ni, “Jẹ ki Mohammed jinde kuro ninu oku, gbogbo aye ni yoo mọ nipa rẹ laarin wakati mẹrinlelogun.”

Bẹẹ ni.

27 Wọn fi ẹṣin kan sibi iboji rẹ. Mo ti ri i nibẹ. Ni wakati mẹrin-mẹrin ni wọn maa n paarọ awọn ẹ̀ṣọ́, wọn n reti ki o jinde - pẹlu afiwe wipe yoo gun ẹṣin funfun wá, lati ṣẹgun aye.

Nitorinaa, o wipe, “Jẹ ki o jinde kuro ninu oku, gbogbo aye ni yoo mọ nipa rẹ.”

O ni, “O dara, Jesu jinde kuro ninu oku.” O ni, “Wolii tiyin wa ninu iboji.”

O ni, “Bawo ni o ṣe mọ wipe O jinde kuro ninu oku?”

Olukọ naa wipe, “O wa ninu ọkan mi.”

O ni, “Mohammed wa ninu ọkan temi naa, sà.”

O ni, “Ṣugbọn emi ni ayọ ati alaafia.”

O ni, “Alagba, ẹsin Mohammed lee mu ọgbọn-ori wa gẹgẹbi ti ẹsin Kristẹni naa.” Wọn si n ṣe bẹẹ. O yẹ ki o gbọ bi wọn ṣe n kigbe ti wọn n pariwo. Bẹẹ ni - wọn lee mu iṣẹ ọpọlọ jade gẹgẹbi ẹsin Kristẹni ti lee ṣe.

O ni, “O dara, kini ẹ n sọ nigbati ẹ wipe Jesu ṣe ileri gbogbo awọn nkan wọnyi?” O ni, “Mo lero wipe o n tọka si Marku 16?”

O ni, “Bẹẹni, ọkan ninu wọn niyẹn - kii ṣe oun nikan, ṣugbọn ọkan niyẹn.”

28 Jesu wipe … Ọrọ ti o sọ kẹyin fun ijọ Rẹ ni 'Ẹ lọ si gbogbo aye [ṣe ẹ ri i], ki ẹ si maa waasu ihinrere. Ami wọnyi ni yoo maa tẹle onigbagbọ. [Titi de ibo? Si gbogbo aye, si gbogbo ẹda.] Bi wọn ba gbe ọwọ wọn le awọn alaisan, ara wọn yoo da. Ọrọ ti o sọ kẹyin niyẹn, ni ibamu pẹlu Iwe Mimọ yin.“

O ni, “O dara, ṣe o mo,” o ni, “iyẹn kan jẹ…” O ni, “Ṣe ẹ ri i, a ko mi si apa ibẹyẹn.” O ni, “Ko ni iyẹn lọkan nitootọ. Iyẹn jẹ…”

29 O ni, “A ko mi si i kẹ?” O ni, “Iru iwe wo ni ẹ n ka?” O ni, “Gbogbo Kurani ni a mi si.” Hmmm.

Iyẹn jẹ ijakulẹ ailera ẹkọ-ẹsin, ẹkọ-ẹsin ti eniyan gbe kalẹ, eyiti ko ni ẹmi lati dide duro doju kọ nkan yẹn. Gẹgẹbi awọn ọmọ Heberu ṣe sọ, “Ọlọrun wa to bẹẹ lati gba wa lọwọ ina ileru yii; ṣugbọn bi o ti wu ki o ri, awa ki yoo foribalẹ fun ere yii.” A nilo awọn eniyan ti o ni igboya. Awọn ti wọn gba Ọlọrun gbọ maa n ni igboya, wọn si gbagbọ ninu iṣẹ iyanu - awọn eniyan ti wọn gba Ọlọrun gbọ.

30 Ọgbẹni Reedhead wipe, “Mo ta ilẹ ni ipa, Arakunrin Branham - mo ta ilẹ ni ipa bẹyẹn. N ko lee da ọkunrin naa lohun.” O ni, “Mo pinnu ninu ọkan mi lati wa ri ọ lẹyin iyẹn. Ohun ti eyi da le lori niyẹn.” O ni, “Emi niyi.” O ni, “Bi Ẹmi Mimọ…” O ni, “Arakunrin Branham, iya mi ran mi lọ si ile-iwe,” o tun wipe, “Mo ti… Nigbati mo gba oye akọkọ BA, mo ro wipe, 'Oun gan-an niyẹn…'”

Mo ni, “Mo mọ ohun ti o n sọ.”

O ni, “Ẹwẹ, lọjọ kan, nigbati mo gba oye akọkọ, BA, mo ro wipe emi yoo ri Kristi nibẹ; ṣugbọn ko si nibẹ. Nigbati mo gba oye kẹta, oye ọmọwe…” O ni, “Mo ti gba oye ti o pọ to, awọn oye ti a fi da mi lọla, lati lẹ mọ ogiri rẹ yii. Nibo wa ni Kristi wa ninu gbogbo rẹ?”

Mo ni, “Ta ni mi lati sọ wipe awọn olukọ kuna. Ṣugbọn iyẹn kọ ni a n sọ. Ẹniti Kristi jẹ gan-an ni o nilo.”

Ẹnikan niyẹn ti o n ṣe isọji nla kaakiri. Ọmọwe Lee Vayle ti o wa nibẹyẹn, ọrẹ mi ọwọn, ọrẹ tirẹ naa ni. O ti ni aṣeyọri nla ni gbigbadura fun awọn alaisan, ati ṣiṣe awọn isọji nla-nla, ati ohun gbogbo. Nitoriti awọn eniyan gbagbọ ni.

31 Ẹ wo o, Ẹmi ti o wa ninu Kristi (ara Jesu, eyiti iṣe Ọlọrun Immanuẹli), Ẹmi Mimọ… Ọlọrun sọkalẹ ninu Kristi, a sọ Ọ di Ọlọrun pẹlu wa. Lẹyinnaa, iyẹn ni lati ra wa pada - ani ẹjẹ Rẹ ti a ta silẹ. Ni bayi, ni Majẹmu Laelae, nigbati olujọsin ba wa, ti o gbe ọwọ rẹ le ọrẹ rẹ, ti o si duubu ọrun rẹ - ti alufaa ṣe bẹẹ - fun ẹbọ naa, olujọsin yoo gbe ọwọ rẹ le ẹbọ naa. Yoo ni imọlara bi a ṣe n ge ẹran-ara ọdọ-aguntan naa, ati bi o ṣe n ku lọ - ẹjẹ rẹ yoo da si irun ara rẹ, ẹjẹ naa yoo da si gbogbo ọwọ onigbagbọ naa, ati bẹẹ bẹẹ lọ, a o si fi àwo gba a, ki a lee sun-un ni ina nibi pẹpẹ - onigbagbọ yoo mọ wipe oun ni o yẹ ki o ku fun ẹṣẹ yẹn, ṣugbọn ọdọ-aguntan naa ni o n ku ni ipo rẹ.

Ṣugbọn ìyè ti o wa ninu ẹjẹ yẹn ko lee pada wa sori olujọsin, nitori ẹjẹ ẹranko ni, eyiti ko ni ọkan. Ṣugbọn ni … nitorinaa, iranti ẹṣẹ wa titi.

32 Ṣugbọn ni bayi, Jesu ti o jẹ Immanuẹli, ìyè Ọlọrun wà ninu Rẹ̀, iyẹn ni o pada wá. Kii ṣe iye eniyan nikan, ṣugbọn Ọlọrun funra Rẹ ni iri Ẹmi Mimọ pada wa, o si sọ yin di ọmọkunrin ati ọmọbinrin Ọlọrun. Ẹ jẹ

ọmọkunrin ati ọmọbinrin eniyan nigbati ẹ ba ni imọlara irora, oṣi ati ijiya ti Jesu la kọja: a fi i ṣe ẹlẹya; wọn pe iṣẹ-iriju iwaasu Rẹ ni iṣẹ eṣu, Beelsebuubu; wọn fi ṣe yẹyẹ, awọn olori ẹsin kẹgan Rẹ̀, wọn kọ ọ silẹ; O tọ awọn tirẹ wa, awọn tirẹ ko si gba a; awọn ohun ti O la kọja ni igba naa, lati fi ẹmi Rẹ rubọ lori agbelebu lati ra awọn ti Ọlọrun ti mọ tẹlẹ pada - ra pada, lati da wọn pada si ipo ibiti wọn ti ṣubu kuro. Ọlọrun ṣe iyẹn lati fi Ẹmi Mimọ ranṣẹ pada sinu ijọ bayi, ki o lee…

Awọn eniyan, awọn onigbagbọ, kiki awọn onigbagbọ nikan ni o wa fun;

33 ko wa fun awọn alaigbagbọ, Wọn ko lee ri i laelae; oku ni wọn lati ilẹ wa. Ẹ wo awọn Farisi wọnyẹn, nigbati wọn ri i ti Jesu ṣe iṣẹ-ami ti o yẹ ki o jẹ ami Messiah. Ẹ wo Peteru. O gba a gbọ lọnakọna, Natanięli naa si gba a gbọ kiakia. Obinrin eti kanga yẹn gba a gbọ, ati Bartimeu afọju. Gbogbo awọn ti o gba a ni o gba a gbọ. Ṣugbọn awọn olori wọnyẹn duro sibẹ, wọn wipe, "Beelsebuubu ni, ẹmi eṣu ni, ọgbọn jibiti kan ni."

Jesu wipe, "Ti ẹ ba sọ iyẹn si mi, emi yoo dariji yin [a koi tii ru ẹbọ naa]. Ṣugbọn nigbati Ẹmi Mimọ ba de lati ṣe nkan kannaa, ti ẹ ba sọ ọrọ kan lodi si i, a ki yoo dari rẹ ji yin laelae, ni aye yii, tabi ni aye ti n bọ." Kini ṣe ti wọn ko lee gba iyẹn gbọ? Jesu wipe, "Ti eṣu baba yin ni ẹyin iṣe, iṣẹ rẹ ni ẹyin si n ṣe." Bẹẹ ni.

34 Lati gba Ọrọ naa gbọ ni lati tẹwọ gba Ọrọ naa, ki o si di iye. Ni bayi, Ọlọrun … o n fihan nibẹyẹn, bi O ṣe n fidi majẹmu naa mulẹ. O nilati ri bẹẹ. Ijọ - kii ṣe ẹgbẹ ti a fi ọgbọn ori eniyan ko jọ o, kii ṣe ijọ ẹlẹkọ-adamọ o, ṣugbọn ẹnikọọkan - Ọlọrun si nilati di Ẹmi kannaa. Ipinnu Ọlọrun niyẹn lati atetekọṣe. Adamu ati Eefa jẹ ẹmi kannaa.

Bibeli sọ ni Gẹnẹsisi 1:27, "Ni aworan Ọlọrun [ẹmi ni Ọlọrun], ni aworan Ọlọrun ni O da a. Ati akọ ati abo ni O da wọn," ni irisi ẹmi ti o wa ninu Ọlọrun. Adamu nilati maa tọju ilẹ, gẹgẹbi o ti yẹ ki Ẹmi Mimọ maa dari ijọ bayi. Sibẹ eniyan koi tii si ninu ẹran ara. O jẹ ati akọ ati abo papọ, nitori ẹmi kannaa ni.

35 Lẹyin eyi, Ọlọrun fi erupẹ ilẹ mọ eniyan, o ṣe e ni iri ẹranko - eyiti a jẹ bayi, ẹranko. A mọ wipe ẹran ti n fun ọmọ ni ọyan ni wa, iyẹn tumọ si ẹranko ti ẹjẹ rẹ lọ wọọrọwọ. A ti wa ni iri iye ẹranko yẹn.

Lẹyin eyi, Ọlọrun mu egungun iha kan lara Adamu. Kii ṣe … obinrin jẹ amujade lati ara ọkunrin, oun ko sí ninu ojulowo ẹda. O mu egungun iha kan. O pin ara naa niya, O si mu ẹmi abo kuro lara Adamu, O fi sinu Eefa. Ọkunrin ati obinrin si wà. Nigbati wọn ba ti kuro ni ipo yẹn, wọn ti kuro ni aaye ti o tọ si wọn. Idibajẹ kan ti wà nibikan, nigbati obinrin ba fẹ maa ṣe bii ọkunrin, tabi ti ọkunrin fẹ maa ṣe bii obinrin. Nkankan ti kuna nibikan. Wọn ti kuro ni ipo ti o tọ si wọn.

36 A kiyesi i wipe ibatan ni Isaaki ati Rebeka jẹ. Iyẹn n ṣe apẹẹrẹ iru-ọmọ Israẹli nipa ti ara. Ṣugbọn nipa igbagbọ, Kristi farahan - ẹniti kii ṣe ti ara. Gẹgẹbi ami ṣe wa ni … ẹjẹ lara atẹrigba ilẹkun ni Egipti. Ko si bi wọn ṣe ni ikọla to, tabi bi wọn ṣe ni majẹmu to, a nilati fi ami naa han, aijẹbẹẹ, majẹmu naa ko ṣiṣẹ. Dajudaju. "Nigbati mo ba ri ẹjẹ naa, emi yoo re yin kọja." Ami naa kii ṣe ẹjẹ; iye ti o wa ninu ẹjẹ ni, ani Ẹmi Mimọ.

Iyẹn si ni … Emi ko bikita bi o ṣe jẹ ẹlẹsin to, bikoṣepe o ba gba Ẹmi Mimọ, iwọ yoo ṣegbe. Ọna kanṣoṣo niyẹn. Ko si ẹsẹ Iwe Mimọ miiran lati ṣe ohunkohun - iyẹn nikan ni. "Ẹ maṣe mu Ẹmi Mimọ Ọlọrun binu, ẹniti a fi ṣe edidi yin de ọjọ idande yin." Efesu 4:30.

37 Ẹ kiyesi i, a pada wa bayi. Iyẹn fihan wipe ọkanṣoṣo ni Adamu ati Eefa lati ilẹ wa. Ọkọ ati aya si nilati jẹ ọkannaa sibẹ. Ṣugbọn nigbati a pin wọn si ọtọọtọ ninu ara, ibẹ ni Eefa ti ṣubu. O ṣubu, kini idi? Nipa aigba Ọrọ naa gbọ - gbogbo rẹ. Awọn kan lee gba apakan Ọrọ naa, ṣugbọn wọn ko lee gba eyiti o ku. Gbogbo rẹ nilati wa nibẹ.

Apakan rẹ ni o ṣe iyemeji rẹ. Njẹ ti gbogbo aisan ati wahala ti a ni bayi ba wá nipa wipe obinrin kan ṣe iyemeji apakan rẹ, bawo ni a ṣe lee ri ohunkohun gba lai jẹ wipe a gba gbogbo rẹ gbọ, ki a si tẹwọ gba gbogbo rẹ? Iyẹn ni tiwọn … Ọrọ yẹn ni aabo wọn. Nigbati a pin wọn sinu ara, wọn ṣubu.

O ṣubu nipa Ọrọ naa. O … ẹ kiyesi i. Kini o n wa?

38 Ọpọlọpọ awọn eniyan loni, wọn n fẹ ọna ti o dara si i - ọna irọrun. Wọn ko fẹ doju kọ ohun ti a gbe ka iwaju wọn.

Ti wọn ba ṣe bẹẹ, wọn yoo lé wọn kuro ninu ijọ ẹlẹkọ-adamọ wọn, wọn yoo le wọn jade sita, wọn ki yoo kà wọn si mọ. Ṣe ẹ ko mọ ni, wipe, "gbogbo eniyan ni yoo maa sọrọ buburu nipa yin nitori orukọ mi. Ẹ maa yọ, ki inu yin ki o si dun gidigidi, nitori ere yin pọ ni ọrun; nitori bẹẹ ni wọn ṣe inunibini si awọn wolii ti o wa ṣaaju yin"? Gbogbo awọn ti o n gbe igbe-aye iwa-bi-Ọlọrun ninu Kristi Jesu yoo farada inunibini.

39 Kini a tun fẹ ki O sọ? Ẹgbẹẹgbẹrun ọrọ ni a lee… ẹsẹ Iwe Mimọ ti o jẹ mọ iyẹn ni a lee ri lati Gẹnẹsisi de Ifihan. Ohunkohun ti a si ni loni, lati Gẹnẹsisi ni o ti bẹrẹ. Oun ni ori irugbin. Gbogbo aigbagbọ ati ohun

gbogbo bẹrẹ nibẹ. Ibẹ ni ijọ ti bẹrẹ. Ibẹ ni ohun gbogbo ti bẹrẹ. O dabi igi ajara meji ti o n dagba, ti ọkan n ṣe afarawe ekeji, ti o si fẹrẹ dabi rẹ gan-an:

40 bii Moabu, ati Mose pẹlu.

Israẹli de ibẹ - ẹgbẹ kekere kan, ti ko ni ijọ ẹlẹkọ-adamọ, wọn kii tilẹ iṣe orilẹ-ede - awọn naa ni iru ẹbọ kannaa nibi yii. Moabu, ijọ ẹlẹkọ-adamọ ti o dara, gbogbo awọn ọtọkulu wọn jade wá, wọn ṣe irubọ kannaa, wọn gbiyanju lati… Bisọọbu wọn ti o wa nibẹ, Balaamu, o sọkalẹ wa lati fi wọn bu, awọn ti Ọlọrun ti bukun fun. Wọn ro wipe, "Awọn ọmọ ita wọnyi - wọn ko tilẹ ni ile-ijọsin kankan, bi o ṣe ri. Alarinkiri ni wọn." O si wipe…

Ṣugbọn wọn kuna lati gbọ igbe ọba yẹn ninu ibudo. O kuna lati ri iwosan atọrunwa ti o n ṣẹlẹ nibẹ nipasẹ ejo yẹn, ati apata ti a lu lati fun wọn ni iye, ariwo ọba ninu ibudo. O kuna lati ri iyẹn - bisọọbu afọju yẹn - ṣugbọn sibẹ, ni ti ẹkọ, oun naa tọna bii ti Mose. Pẹpẹ meje, ẹbọ meje, o tilẹ fi agbo rubọ, eyiti o n sọrọ nipa bibọ Kristi.

41 Ṣugbọn Ọlọrun ko nilo ẹnikẹni lati tumọ Rẹ; Oun ni olutumọ ara Rẹ. Yoo ṣe ileri, yoo si mu u ṣẹ, itumọ rẹ niyẹn. Ẹnikẹni ko nilo lati tumọ rẹ. Ọlọrun ko beere lọwọ ẹnikẹni. Bibeli ko ni itumọ ikọọkọ. Olukuluku n gbiyanju lati sọ wipe o tumọ si eyi, ati iyẹn… Ẹ jẹ ki Ọlọrun sọrọ funra Rẹ. Oun ni o n ṣe e. Oun ni o ṣe ileri; O si duro ti i. O n ṣe bẹẹ fun awọn onigbagbọ; ṣugbọn awọn alaigbagbọ ko ri ohunkohun gba. Ko wa fun wọn; oku ni wọn lati ilẹ wá. Wọn ko fi igba kankan ni ikọ̀ rara. Ko si ohunkohun ninu wọn - oku lasan ni wọn. Ẹyin ko fẹ ri bẹẹ. Ẹ kun fun Ẹmi.

42 Ẹ kiyesi i, O pin Eefa ati Adamu si ọtọọtọ, oun si ṣubu. Adamu naa tẹle e. Ni bayi, a ko tan Adamu jẹ; Eefa ni a tan jẹ. Ṣugbọn Adamu, Adamu akọkọ, ọmọ Ọlọrun ni, ṣugbọn o jade lọ nitori ifẹ Eefa - o gbiyanju lati mu u pada wa, nitoriti o fẹran rẹ. Kristi ṣe nkan kannaa lati ra a pada. Si kini? Si Ọrọ naa! Kini o fa iṣubu? Ọrọ naa ni, aigba Ọrọ naa gbọ, ani gbogbo Ọrọ naa. Kristi wa, lati di ọkan lara wa, ki iye Rẹ wa ninu wa, lati mu ki Ọrọ naa tẹsiwaju. "Ni atetekọṣe ni Ọrọ wa, Ọrọ si wa pẹlu Ọlọrun, Ọlọrun si ni Ọrọ naa … Ọrọ naa si di ara, O n ba wa gbe," ọkannaa lana, loni, ati titi lae - Ọlọrun kannaa ni. Idi ti o fi wa ṣe iyẹn niyẹn. A ri i ninu ifidimulẹ, O ra wa pada si ọdọ ara Rẹ, O ra awọn aṣako ọmọ pada, awọn ti wọn ti ṣako lọ sinu ile igbokupamọ si wọnyi … O mu wọn pada wa sinu Ọrọ naa, pada sinu Ọrọ naa ti a fihan.

43 Njẹ awọn Juu wọnyẹn, nigbati Jesu de, wọn lee wipe, "A ni Ọrọ naa! A ni Ọrọ naa! Ohun ti Mose sọ niyi. Ọmọ-ẹyin Mose ni awa." Jesu, ọmọ ọdun mejila pere, n ba wọn jiyan, lẹyin eyi, nigbati… Ṣe ẹ ri i, ohun ti eniyan ṣe si i niyẹn.

Ṣugbọn Jesu wipe, "Bi emi ko ba ṣe iṣẹ Baba mi, ẹ maṣe gba mi gbọ. Nitori iṣẹ ti Baba ti fi fun mi lati ṣe, wọn n jẹri ẹniti mo jẹ." Ẹnikẹni ti o ba jẹ ọmọ Ọlọrun, Ọlọrun yoo jẹri si iṣẹ ti a ti yan-an lati ṣe. Ti ko ba ri bẹẹ, a jẹ wipe Iwe Mimọ ko ti i lẹyin, fi i silẹ.

44 Ni Majẹmu Laelae paapaa, wọn ni ọna ti wọn fi n mọ boya otitọ ni tabi bẹẹkọ. Wọn yoo mu wọn lọ - alala kan, tabi alasọtẹlẹ kan, tabi ẹnikẹni yoowu ti o jẹ - wọn yoo mu u lọ si ibi Urimu ati Tumimu. Iyẹn ni imọlẹ iyanu. Ọlọrun jẹ iyanu nigbagbogbo, o maa n ṣiṣẹ ni ọna iyanu. Niwọn igba ti Ọlọrun ba wa nibẹ, iyanu wa nibẹ, iyẹn ti o ba jẹ Jehofa Ọlọrun. Njẹ nigbati … ko si bi ala naa ṣe dara to, ti ko ba tan ina lara Urimu ati Tumimu yẹn, o lodi.

Njẹ ni bayi, ilana alufaa ti Aaroni atijọ ti kọja lọ, ṣugbọn sibẹ, a ṣì ni Urimu ati Tumimu. Eyi ni ifihan Jesu Kristi - ti o fi Oun han ninu Ọrọ yii. Ohunkohun ti o ba lodi si Ọrọ yẹn kii ṣe Ọlọrun - o lodi si i. Ṣugbọn Ọlọrun maa n sọrọ funra Rẹ. O maa n fi ara Rẹ han nipa Ọrọ Rẹ. Ibi ti Jesu ti ṣẹgun Satani niyẹn - "A ti kọ ọ."

Satani tun pada wa, o tun kuna. O ni, "Bẹẹni, a tun ti kọ ọ…"

Ṣugbọn ni igba yẹn, nigbati o wa, o kọlu agbara ina nla. Ni akoko naa, iye rẹ rẹ̀ danu. O sa kuro nibẹ nigbanaa. O ni, "A ti kọ ọ pe, "Eniyan ki yoo wa laaye nipa akara nikan, ṣugbọn nipa gbogbo ọrọ ti o ti ẹnu Ọlọrun jade. Pada lẹyin mi, Satani!"

45 Ẹ kiyesi ohun ti o ṣẹlẹ. Ọlọrun maa n fi ara Rẹ han nipa Ọrọ ileri Rẹ. Iba ṣe wipe awọn Farisi wọnyẹn wo ẹyin wo ni, Mose wipe, "Oluwa Ọlọrun rẹ yoo gbe wolii kan dide fun ọ bii temi." Iyẹn wa ninu Iwe Mimọ.

Abajọ ti Jesu fi dupẹ lọwọ Baba, O ni, "Mo dupẹ lọwọ Rẹ, Baba, Iwọ ti fi eyi pamọ kuro loju awọn ọlọgbọn ati amoye; O si fihan fun awọn ọmọ-ọwọ, awọn ti yoo kẹkọ." Nigbati O sọ fun Peteru ni ọjọ yẹn, nigbati O sọkalẹ wa, ti o wipe, "Tani awọn eniyan n fi emi Ọmọ eniyan pe? ..."

Ọkan ninu wọn sọ pe, "Iwọ ni Elijah," ọkan tun wipe, "Iwọ ni Mose," ati bẹẹ bẹẹ lọ.

O ni, "Ṣugbọn kii ṣe ibeere ti mo n bi yin niyẹn."

O ni, “Iwọ ni Kristi naa, Ọmọ Ọlọrun alaaye.”

O ni, “Alabukunfun ni iwọ Simoni, ọmọ Jona. Ẹran-ara ati ẹjẹ ko ṣaa fi eyi han ọ [o ko kọ ọ ni ile-ẹkọ ẹsin, ko si ẹniti o kọ ọ, ṣugbọn ifihan ni. Akiika!]. Ori apata yii ni Emi yoo kọ ijọ mi le, ẹnu-ọna ipo oku ki yoo si lee bori rẹ [ifihan, tabi idanimọ ẹniti Jesu Kristi jẹ].” O ni, “Bi emi ko ba ṣe iṣẹ Baba mi, ẹ maṣe gba mi gbọ.”

46 Ẹ jẹ ki a tẹsiwaju bayi. A ri Oun bayi - ẹ jẹ ki a lọ si ori ikẹtadinlogun. A ri Oun ni ori ikẹtadinlogun, nibiti o ti farahan fun Abrahamu lẹyin ifidimulẹ eyi, O n fi ohun ti Oun yoo ṣe han. Ẹ ranti bayi, Ẹmi sọkalẹ sori… Ẹmi ti o wa ninu ijọ - ojulowo ijọ, ijọ tootọ, ijọ Ọlọrun, awọn eniyan Ọlọrun - Ẹmi ti o wa ninu wọn n bẹ ninu … Ẹmi kannaa ni o wa ninu Kristi, pẹlu ileri wipe, “Iṣẹ ti mo ṣe ni ẹyin naa yoo ṣe pẹlu.”

47 Ẹ ranti igba kan, nibi kikan mọ agbelebu (ṣaaju igba yẹn), wọn fi akisa bo oju Rẹ, wọn fi ọpa lu u ni ori. Wọn ni, “Ni bayi, bi Iwọ ba jẹ Ọmọ Ọlọrun … wọn sọ fun mi wipe wolii ni ọ. Sọtẹlẹ, iwọ wolii!” Wọn ju ọpa naa si ara wọn. “Sọ fun wa, tani o lu ọ.” Ṣe ẹ ri eṣu yẹn? Ṣe ẹ ri i, o wipe, “Mo gbọ wipe oniṣẹ-iyanu nla ni ọ. Sọ awọn okuta wọnyi di akara. Jẹ ki n ri Ọ ki O ṣe e. Emi yoo gba Ọ gbọ ti O ba lee ṣe e bẹyẹn. Sọ awọn okuta wọnyi di akara. Emi yoo gbagbọ ti O ba ṣe e.”

48 Ọkunrin kan sọ fun mi laipẹ yii, o ni, “Ti o ba lee mu ẹnikan wa ti o ti ri iwosan, pẹlu akọsilẹ ẹri dokita…”

Mo ni, “Ọlọrun ṣaanu, pa ẹnu rẹ mọ, iwọ ọkunrin yii. Nitori Ọlọrun,” mo ni, “emi yoo mu ọgọọgọrun awọn dokita wa.”

O ni, “Mo ni ẹgbẹrun dọla kan ti o n duro de ọ ti o ba ṣe e.” Mo si ko awọn dokita wa, awọn ti o n tọju aisan naa.

O ni, “Ko buru, owo naa wa ni…”

Mo ni, “Mo n fẹ owo naa fun ọrẹ ikiriwaasu.”

O si wipe…

“…lati ran ẹnikan ti o gba ihinrere gbọ lọ si oke okun.”

O ni, “Ko buru, jẹ ki n mu ọmọdebinrin kan wa, emi ati arakunrin mi yoo duro sibẹ, a o si ge ọwọ rẹ̀. Ki iwọ wo o san niwaju wa, a o si gba ọ gbọ.”

Mo ni, “O nilo iwosan ọpọlọ.” Bẹẹ ni nitootọ - ẹniti o kun fun ẹmi eṣu to iyẹn!

Oun kannaa ni o sọ pe, “Bi iwọ ba iṣe Ọmọ Ọlọrun [bi iwọ ba iṣe], sọkalẹ lati ori agbelebu,” nigbati Bibeli sọ pe a o gbe e kọ sori agbelebu.

Kaiafa sọ pe, “O gba awọn ẹlomiran la; ara Rẹ ni ko lee gbala,” lai mọ wipe oriyin ti o ga ju ni oun n gbe fun-un. Ti O ba gba ara Rẹ la, ko ni lee gba awọn ẹlomiran la. O nilati jọwọ ara Rẹ.

Lootọ, O mọ ẹniti o lu Oun, ṣugbọn ko ba eṣu da awada. Ọlọrun kii ṣe alawada. Kii ba eṣu da awada. A maa n fi iṣẹ Rẹ ranṣẹ si awọn ti o gba a gbọ; kii ṣe lati maa fi ṣe awada.

49 Ẹ kiyesi i. O farahan fun-un nigbati o pe ọmọ ọdun mọkandinlọgọrun, O si fara han-an ni orukọ Ọlọrun Olodumare. Orukọ yẹn ni ede Heberu ni El Shaddai.

Ọlọrun ní orukọ irapada meje. A mọ bẹẹ, o ko si lee ya wọn sọtọ kuro lara Kristi. O ko lee ya wọn sọtọ. Kristi ba gbogbo awọn orukọ irapada yẹn mu. Ṣe ẹ gba iyẹn gbọ? Ṣe ẹ gbagbọ wipe Oun ni Jehofa-jire, ẹbọ ti Oluwa pese? Jehofa-rafa nkọ, Oluwa wo gbogbo aisan rẹ san? Ti iyẹn ko ba ba Kristi mu, a jẹ wipe Oun kii ṣe Jehofa-jire. O ko lee ya wọn sọtọ. A so gbogbo rẹ papọ ni, bi o ṣe ri niyẹn. Ko lee jẹ Jehofa-rafa lai jẹ Jehofa-jire, ko si lee jẹ Jehofa-jire lai jẹ Jehofa-rafa. A pa a lara nitori aiṣedeede wa, nipa ina Rẹ ni a mu wa lara da. Ko si iyan jija nipa iyẹn.

50 A ri i wipe O farahan nibi yii ni orukọ El Shaddai, Olodumare. Lootọ, ọrọ yẹn, ọrọ Heberu yẹn “shad,” s-h-a-d (awọn kan n pe e ni “shade”), “shad” tumọ si ọyan, gẹgẹbi ọyan obinrin. O farahan fun-un ni orukọ El Shaddai, eyiti o jẹ ilọpo meji, ọyan meji. “Emi ni Ọlọrun ti o ni ọyan meji. Abrahamu [ọmọ ọdun mọkandinlọgọrun], maa rin niwaju mi. Jẹ pipe. Gba Ọrọ mi gbọ, ṣaa maa gbagbọ. Mo ṣe ileri nigbati o jẹ ọmọ ọdun marundinlọgọrin. Ó ti pe ọdun mẹrinlelogun bayi lati igba ti mo ti ṣe ileri naa fun ọ.”

Itunu ni o nilati jẹ fun baba arugbo ọmọ ọdun mọkandinlọgọrun, gbogbo okun rẹ ti lọ, Ọlọrun si wá duro siwaju rẹ, O ni, “Emi ni El Shaddai. Emi ni Ọlọrun ti o ni ọyan. [Amin!] Gba okun rẹ lati ọdọ mi. Emi ni okun rẹ. [Gẹgẹbi Majẹmu Titun ati Laelae, Ọlọrun ti o ni ọyan meji.] Emi ni Ọlọrun ti o ni ọyan. Gba okun rẹ lati ara mi.” Bi igba ti ọmọ-ọwọ ba n ṣe aisan, ti o n gbọn, ti ara rẹ ko ya, aarẹ mu u - yoo sun le ọyan iya rẹ, yoo si

fa okun pada lati ara iya rẹ. Iyẹn ni wipe, “Abrahamu, ọmọ-ọwọ ni o jẹ si mi, iwọ ọmọ ọdun mọkandinlọgọrun. Iyẹn kii ṣe akoko rara.” Igbe-aye rẹ… Ẹ ranti, o dabi ẹni wipe ana ni a kan Jesu mo agbelebu. Ẹgbẹrun ọdun kan lori ilẹ aye jẹ ọjọ kanṣoṣo niwaju Ọlọrun. Ṣe ẹ ri i, bi ẹni wipe ana ni a kan-an mọ agbelebu.

51 Ẹ kiyesi i, “Emi ni El Shaddai. Iwọ ni ọmọ-ọwọ ti o n saarẹ. Ṣugbọn simi le aya mi, ileri mi, ki o si fa okun rẹ lati ara mi. Emi ni ẹlẹda ti o so ọrun oun aye ro, emi ni mo fi awọn irawọ sibẹ. Ohunkohun ha ṣoro fun Ọlọrun bi? Emi ni El Shaddai, iwọ si ni ọmọ mi, looto o ṣe alailera. Emi ni mo jẹ ki o ri bẹẹ, lati lee mọ ohun ti iwọ yoo ṣe nipa rẹ. Emi yoo fi eyi ṣe apẹẹrẹ fun awọn eniyan lẹyin akoko yii, ki awọn eniyan lee maa gba ọrọ mi gbọ. Emi yoo duro ti i, ohun yoowu ti yoo na mi, bi o ti wu ki o pẹ to - emi yoo ṣe e. Emi yoo duro ti i.” El Shaddai. “Fa okun rẹ lati ara mi.”

O lee wipe, “Ah, iba ṣe wipe mo lee gbagbọ ni…” Oun ṣì jẹ El Shaddai sibẹ. Oun si jẹ Ọlọrun ti o ni ọyan meji sibẹ, Majẹmu Titun ati Laelae. Ṣaa maa fa okun rẹ lati ara Rẹ̀, ohunkohun yoowu ti o ba nilo. Ọmọ-ọwọ naa ko lee ran ara rẹ lọwọ. O nilati fa okun lati ara iya rẹ. Ọna kanṣoṣo ti o fi lee ni okun niyẹn. Ọna kanṣoṣo ti onigbagbọ fi lee ni okun niyẹn, ni lati fa a lati inu Ọrọ Ọlọrun. Okun rẹ niyẹn, ani ileri Ọlọrun fun-un. Duro, ki o si gba a gbọ.

52 Kii ṣe wipe a fi ọmọ-ọwọ ṣe apẹẹrẹ nibi yii nikan, nigbati aisan ba n ṣe e ti o si n gbọn - iya rẹ lee gbe si ibi ọyan rẹ, yoo si maa fa okun rẹ pada - yoo ni itẹlọrun bi o ṣe n jẹun. Bi o ṣe ri pẹlu ojulowo ọmọ Ọlọrun niyẹn. Ohun yoowu ti oniyemeji ba sọ, ohunkohun ti o gbagbọ - ti o ba gba a gbọ nitootọ, Jesu ko lee purọ! O ni itẹlọrun wipe a ti fihan fun ọ. O ti gba ileri naa, ko si si ohun o lee da a duro. “Ori apata yii ni emi yoo kọ ijọ mi le”: Ọrọ otitọ ti a fihan nipa ti ẹmi.

53 Bi o ṣe n duro, ti o n simi lori igbagbọ rẹ, gba ileri Ọlọrun. “Mo gba Ọ gbọ, Oluwa. O ṣe ileri lati fun mi ni baptisiimu Ẹmi Mimọ. Mo n simi ninu … igbagbọ, igbagbọ ti mo ni ninu Rẹ. Mo n gba lati inu orisun mi … orisun mi lati … fun ilera mi lati orisun Rẹ, ani Ọrọ naa.” Eniyan ki yoo wa laaye nipa akara nikan, ṣugbọn lati ookan aya Ọlọrun ni yoo ti fa okun rẹ. Gbogbo ọrọ ti o ti ẹnu Ọlọrun jade, ni yoo fi maa gba okun bi o ṣe n … jade lati ẹnu Ọlọrun, ani Ọrọ naa.

54 Gẹgẹbi Abrahamu - Abrahamu n simi. O ti n ba Sarah gbe lati igba ti o ti wa ni ọdọmọbinrin. Ọmọ baba rẹ ni. O n gbe pẹlu rẹ, o si fẹ ẹ. O ti ni … o yagan. Ko ni ọmọ kankan. Oun si niyi, o ti… Ti oun ba jẹ aadọrun, tabi mọkandinlọgọrun; oun jẹ ọmọ ọdun mọkandinlaadọrun - ọmọ ọdun mọkandinlaadọrun! Ṣugbọn, “Abrahamu, simi ninu igbagbọ Ọrọ Mi. Mo ṣe ileri fun ọ wipe n o ṣe e. Emi ni El Shaddai. Emi ni Ọlọrun ti o ni ọyan fun awọn ọmọ mi ti o gbagbọ.” Ti iwọ ko ba fẹ gba agbara, maṣe sọ ohunkohun nipa rẹ mọ. Ṣugbọn ti o ba jẹ ọmọde, o n jẹun lati gba agbara, o n simi lori gbogbo ileri.

55 Ẹ kiyesi i, ojulowo igbagbọ maa n simi le apata ileri Ọrọ Ọlọrun ti o duro gbọin. Kii yẹ. Igbagbọ tootọ ni idakọro, gẹgẹbi Irawọ Ariwa. Irawọ Ariwa jẹ idakọro fun gbogbo atukọ oju-omi. Irawọ Ariwa yẹn nikan ni atọka yoo tọka rẹ si. Ọlọrun, ẹniti iṣe Ọrọ, ni Irawọ Ariwa fun gbogbo Kristẹni, ti o ba sọnu. Ẹmi Mimọ ni o si n tọka rẹ si i. Ki yoo tọka si ohun miiran. Gbogbo ẹkọ-adamọ ti o ku, ati bẹẹ bẹẹ lọ, pẹlu ẹsin Kristẹni ti wọn dapọ mọ ọ, ohun yoowu ti o lee jẹ, o dabi aye ti o n yi. O maa n yi awọn irawọ yẹn pada; ṣugbọn ko lee yi Irawọ Ariwa pada. Bẹẹni ko si ohunkohun ti o lee yi Ọrọ Ọlọrun pada. Duro lori rẹ. Duro ti i.

Ojulowo igbagbọ kii yipada nipa ẹkọ-adamọ, ati ẹkọ eniyan ati aigbagbọ. O maa n duro lori Ọrọ naa ni - igbagbọ tootọ ninu Ọrọ naa. Inu kini o tun lee fi igbagbọ rẹ si yatọ si Ọrọ naa? Ti Ọlọrun ba ti sọ bẹẹ, di i mu, otitọ ni. Kii yipada. O n fa lati inu iwe Ọlọrun ti o ni ọyan, ani Bibeli, o n fa awọn ero Ọlọrun, awọn ohun ti O ṣe ileri. Ohun ti O ṣe ileri naa ni Ọrọ Rẹ. Ọrọ naa n fi ara rẹ han. O nilati kọkọ jẹ ero ki o to di Ọrọ, lẹyinnaa Ọrọ, lẹyinnaa, Ọrọ naa yoo farahan; ibi ti iwọ yoo ti gba agbara rẹ niyẹn. Maa gbagbọ, gba Ẹlẹda gbọ, maa gbagbọ wipe Oun ni Ẹlẹda ti o da aye.

56 Majẹmu Titun sọ nibẹyẹn, wipe, “Gẹgẹbi Mose ti gbe ejo soke ni aginju, bẹẹ naa ni a gbọdọ gbe Ọmọ eniyan soke.” Fun idi kannaa ni - kini? Wọn n ṣiyemeji Ọlọrun, aisan ati wahala si wọle de. Kini O gbe ejo naa soke fun? Fun iwosan wọn, ati fun idariji wọn. Idi niyẹn ti… Idẹ si n ṣe apẹẹrẹ idajọ atọrunwa. Jesu ni ejo naa ti a ṣe idajọ rẹ, bẹẹni. Idẹ naa..

57 Nigbati … lẹyin ti O ti fidi majẹmu naa mulẹ, tabi ti a ti fi majẹmu naa han fun-un, o n fun awọn ọmọ Ọlọrun tootọ ni igbagbọ. Ọrọ naa n funni ni igbagbọ - Eni naa ti o ni ọyan. O n ṣe nkankan fun wọn nigbati Ọrọ naa … nigbati a fi majẹmu naa han - o fun awọn ọmọ Ọlọrun tootọ ni igbagbọ.

58 A ri i wipe a pe e ni Ẹlohiimu nibi yii. Ọrọ naa tumọ si Ẹlohiimu nibi yii. Mo ṣẹṣẹ wo o lati ni idaniloju ni - Ẹlohiimu. Ẹlohiimu ni ẹniti o danikan to funra Rẹ. Oun ni El Shaddai, Ẹlohiimu, Ọlọrun ti o ni ọyan, ẹniti o danikan to funra Rẹ. Ko nilo ohunkohun lati ọdọ ẹnikẹni. Oun ni gbogbo tito rẹ.

59 Ẹ kiyesi i, a jẹri nkan kannaa nibi yii (mo kiyesi i ni ọsan yii nigbati mo n ṣe àṣàrò), ninu iwe Joobu.

Joobu - a pe e ni Ẹlohiimu. A fi Joobu ṣe ẹlẹya, a fi ṣe yẹyẹ. Bawo … aworan ọjọ oni niyẹn. Ṣugbọn Joobu n simi ninu ileri Ẹlohiimu: “Lẹyin ti idin ba ti jẹ ara yii, sibẹ ninu ẹran ara mi ni emi yoo ri Ọlọrun, ẹniti emi yoo ri funra mi.” Maa simi ninu Ẹlohiimu, ohun yoowu ti o ṣẹlẹ.

Iyawo rẹ wá, o ni, “Oju rẹ ko dara rara, Joobu.”

Awọn olutunu rẹ naa wa. “Ah-a-ah, ṣe o ri ohun ti o ṣẹlẹ si ọ bayi, ọmọ. Mo sọ fun ọ wipe o kuna tẹlẹ.” Ṣe ẹ ri ohun ti o ṣẹlẹ? Ọpọ awọn eniyan ni wọn maa n fẹ sọrọ si iru awọn eniyan bẹyẹn. Joobu ni eniyan ti o dara ju ni ọjọ tirẹ. Eniyan ti o dara ju ti Ọlọrun ni lori ilẹ aye ni Joobu. O sọ fun Satani wipe, “Ko si ẹni bii tirẹ. [Amin!] Njẹ o ti ronu nipa rẹ bi?”

Satani wipe, “Bẹẹni. Ohun gbogbo ni o rọrun fun-un. Ṣí ọgba yẹn, ki o si jẹ ki n fi ọwọ ba a. Emi yoo mu ki o bu Ọ loju ara Rẹ.” O sa gbogbo ipa rẹ, ṣugbọn ko le ṣe e; Joobu simi ninu ileri naa.

60 Awọn kan wa, wọn wipe, “Ọlọrun ti o n sọrọ nipa Rẹ da bayi? Uh-huh. Wo ohun ti o … o gbagbọ lati jẹ… Wo o. Wo ohun ti o n ṣẹlẹ bayi.”

Ṣugbọn sibẹ, o n simi ninu El Shaddai, bi o tilẹ jẹ wipe ọpọlọpọ eéwo ni o n yọ ni ara rẹ, o si dabi ẹni wipe ẹmi rẹ ti bọ. O joko sori ebè eérú, o n ha eewo rẹ. Iyawo rẹ wipe, “Kini ṣe ti o ko fi Ọlọrun bu, ki o si ku?”

O ni, “Iwọ n sọrọ gẹgẹbi aṣiwere obinrin. [Akiika!] Oluwa fi funni, Oluwa si gba lọ. Ibukun ni fun orukọ Oluwa. Mo gbagbọ ninu Ẹlohiimu. Bi o tilẹ pa ara yii run, ti awọn idin jẹ ẹ; sibẹ ninu ara mi ni emi yoo ri Ọlọrun, ẹniti emi yoo ri funra mi. Oju mi yoo ri i, kii ṣe ẹlomiran.”

O jade sita ni Matteu 27 nigbati awọn ẹni mimọ jinde - o jade wa, o si wọle. Ṣugbọn (o wọ inu ilu naa), apẹẹrẹ ọjọ oni ni; sibẹ o duro, o gbẹkẹle ileri naa.

61 Ẹ kiyesi i, lẹyin ti O farahan ni orukọ yii, orukọ Ọlọrun Olodumare… Ni bayi, ẹyin ijọ, a le kọ wa ni ẹkọ kekere kan bayi, eyiti o lee ru yin loju diẹ. Ti o ko ba gba a gbọ, o ku si ọwọ rẹ. A wa nibi … Emi yoo sọ ohun ti mo ro. Iwọ ni ẹtọ lati ro ohun ti o ba fẹ ro.

Ṣugbọn ẹ kiyesi i - ṣugbọn gbogbo awọn nkan wọnyi jẹ apẹẹrẹ, ojiji, ati apẹẹrẹ, bi Bibeli ṣe sọ wipe wọn jẹ. Gbogbo wọn wa nibẹ. Ọlọrun ni o n ba Abrahamu lo ninu irin-ajo yii, gẹgẹbi yoo ṣe ba iru-ọmọ alade Abrahamu lo ninu irin-ajo wọn.

Ẹ kiyesi i, bakannaa ni O ṣe n ba awọn Juu lo. Gbogbo rẹ bẹrẹ ninu ileri majẹmu yẹn - gbogbo orilẹ-ede, gbogbo eniyan.

62 Ẹ kiyesi i, lẹyin ti O farahan ni orukọ Ọlọrun Olodumare, a fihan fun-un wipe Oun ni Ẹniti o danikan to funra Rẹ. Ko ni oluranlọwọ kankan; ko nilo akọwe kankan. Oun nikan ni Ọlọrun. Oun nikan ni Ọlọrun. O si farahan fun Abrahamu ni orukọ yii. Nigbati O farahan fun-un ni orukọ yii, ti Abrahamu si mọ ẹniti O jẹ, O yi orukọ Abrahamu pada.

Ni bayi, o ti de ibi ẹkunrẹrẹ igbagbọ. Ṣe ẹ ri ibiti ijọ de? Mo lero wipe ẹ lee mọ adiitu naa. O de ibikan ti o jẹ wipe O fi ẹniti Oun jẹ han fun-un, lẹyin eyi, O yi orukọ Abrahamu pada, ki a lee mu ileri naa ṣẹ.

Iwọ sọ wipe ko si nkankan ninu orukọ. Eeṣe ti O fi yi orukọ Abrahamu pada lati Abramu si Abrahamu? Eeṣe ti O fi yi orukọ Jakọbu pada kuro ni Jakọbu (ajin-ni-lẹsẹ) si Israẹli (ọmọ-alade pẹlu Ọlọrun)? Eeṣe ti O fi yi orukọ Sọọlu pada si Pọọlu? Dajudaju, orukọ rẹ… Dajudaju. Dajudaju, o tumọ si nkankan - o ri bẹẹ daju. Ti a ko ba sọ ọ ni orukọ ti o dara, Ọlọrun yoo yi i pada ti O ba pe ọ. Bẹẹni, sà.

63 Ẹ kiyesi i, O yi orukọ rẹ pada lati Abram si Abrahamu, eyiti o tumọ si baba orilẹ-ede pupọ - o fi h-a-m kun-un, Abrahamu. O ṣe eyi ki a lee mu ileri naa ṣẹ lẹkunrẹrẹ; ati ki a lee ri ọmọ naa ti a ti ṣe ileri rẹ fun ọjọ pipẹ, tabi ki a lee fihan. Nigbati O yi orukọ rẹ pada, ti O si… Lẹyin ti o ti mọ ẹniti O jẹ, o lee jẹ wipe … o lee ro wipe wọn pọ. Ṣugbọn o mọ wipe Oun ni Ẹlohiimu - Ọlọrun nikan. Ṣugbọn nigbati o ṣe bẹẹ, O yi orukọ rẹ pada.

O ni, “Wayi o, Abrahamu, a ki yoo pe ọ ni Abramu mọ, ṣugbọn Abrahamu; nitori mo ti ṣe ọ ni baba orilẹ-ede pupọ - Abrahamu.” O ti wa ni ipo naa bayi. O ti wa ni ipo… Lẹyin ifihan ẹniti O jẹ, o ti wa ni ipo lati ri ọmọ naa.

64 Ọmọ naa ti ṣetan lati wa, ki a fi i han.

Ah, ẹyin ọmọ Abrahamu, ẹ kiyesi i. O yi orukọ ojiṣẹ Rẹ pada ni igba ikẹyin, nigbati o pe ọmọ ọdun mọkandinlọgọrun, lẹyin ti o ku ọdun kan pere. O yi orukọ rẹ pada lati Abramu si Abrahamu. Ni yiyi orukọ rẹ

pada, o fi h-a-m kun-un, eyiti o tumọ si baba. O ti fẹ di baba, baba ileri kan - baba ileri.

Ti o ba ni imọ-ẹmi-yati ti ẹmi, feti silẹ. Lẹyin ifihan orukọ rẹ, ti ẹniti O jẹ, O yi orukọ rẹ pada. Lẹyin ti ifihan naa ti wa si aye bayi - wipe kii ṣe ọlọrun pupọ; ṣugbọn ẹyọkan ni o wà - akoko ti to bayi fun ifihan Ọmọ naa, eyiti a ṣe ileri wipe a o fihan fun iru-ọmọ alade ileri Abrahamu.

65 Ẹ wo o. O yi i pada lati Wesley, Onitẹbọmi, Alagba, Afede-ajeji-sẹri-Ẹmi-Mimọ. Emi ko mọ boya ki n sọ eyi tabi bẹẹkọ. O ko nilo lati gba a gbọ. Ṣugbọn mo lero wipe ẹ o dariji mi, nitori n ko fẹ ṣe ohun ti o dun yin. Ṣugbọn ẹ wo o. Ko si ojiṣẹ kankan si awọn ijọ Ọlọrun ri, ninu gbogbo itan akoko, eyiti o ni olori kan lati igba atunṣe, gẹgẹbi olori ti a ni loni - Billy Graham. Bẹẹ ni, nitoriti o ti lọ si gbogbo aye, ṣe e ri i.

E kiyesi i. A ko ni ọkunrin kan ri… Ninu gbogbo awọn alatunṣe ti a lee sọ: Sankey, Moody, Finney, Calvin, Knox, eni yoowu ti o lee jẹ, Wesley, Luther; ko si eyiti orukọ rẹ pari si h-a-m ri. Ojiṣẹ kanṣoṣo ti a ni ninu gbogbo awọn igba ijọ, eyiti orukọ rẹ pari pẹlu h-a-m - G-r-a-h-a-m, Graham. Graham jẹ lẹta mẹfa, mẹfa si ni iye eniyan, ọjọ eniyan. A da eniyan, ni Gẹnẹsisi 1:26, ni ọjọ kefa. Ṣugbọn meje ni iye ti Ọlọrun. Ni ọjọ kẹjẹ, Ọlọrun simi - kii ṣe ọjọ kẹfa, o fihan wipe G-r-a-h-a-m yii yoo wa fun awọn ijọ aye.

Ṣugbọn A-b-r-a-h-a-m, Abraham, jẹ lẹta meje.

66 O lee wipe, "Ko si nkankan ninu nọmba." A jẹ wipe o ko mọ awọn nọmba Bibeli rẹ. Iwọ yoo ṣì i bayi. Dajudaju. Ọlọrun pé ninu mẹta, a maa n sin-in ninu meje, ati aadọta, ati ogoji, ati jubili ti iṣe aadọta. Ohunkohun ti o ba fẹ… Gbogbo Bibeli n lọ pẹlu iṣiro. Ẹ kiyesi, ikẹfa jẹ ojiṣẹ ti a o ran si aye. Ẹ tun kiyesi i, meje ni nọmba Ọlọrun.

Ẹ kiyesi i, ni akoko ifarahan yii, nipa ifihan ọmọ naa, nigbati a o fi i han - iyẹn ọmọ naa - wọn ti mọ orukọ rẹ, wọn mọ ẹniti O jẹ. Oun ni El Shaddai, Olodumare, Ẹlohiimu. Ṣugbọn bayi, a ti de akoko ti ọmọ ileri naa yoo fi ara rẹ han. Ọmọ naa - Isaaki funra rẹ - ni a ti ṣe ileri, o si ti ṣetan lati farahan ni gbangba. Ko si lee ṣe e bikoṣe igba ti O kọkọ ranṣẹ, ti O si yi orukọ rẹ pada lati Abramu si Abrahamu, nitori baba orilẹ-ede pupọ ni oun iṣe.

Ẹ kiyesi i, "ham," h-a-m, baba, baba orilẹ-ede pupọ.

67 Ẹ wo bi iyẹn ṣe ba Malaki ori kẹrin mu to - da igbagbọ pada si ti awọn baba - a n da iru-ọmọ Abrahamu pada si iru igbagbọ eyiti baba Abrahamu ni, iru-ọmọ alade rẹ. Imuṣẹ Malaki ori kẹrin ni yoo da igbagbọ naa pada, eyiti o ti kọkọ wa ni ibẹrẹ - a o da a pada fun iru-ọmọ alade Abrahamu.

Ileri ni. Ileri gidi ni. A nilati fi iru-ọmọ alade naa han, ati nipa … iru-ọmọ alade naa, eyiti iṣe iru-ọmọ alade Kristi. Kristi ni iru-ọmọ alade naa. Iru naa si ni Ẹmi Mimọ ti o wa ninu ọkan awọn eniyan ti o gba Ọlọrun gbọ, ti o di Ọrọ Rẹ mu, Ọlọrun si n ṣiṣẹ ninu wọn, O n gbe iru iṣẹ-iranṣẹ iwaasu kannaa dani. "Ni igba diẹ si i, aye ki yoo ri mi mọ; ṣugbọn ẹyin yoo ri mi. Emi yoo wa pẹlu yin, ani ninu yin, iṣẹ ti mo ṣe, ni ẹyin naa yoo ṣe pẹlu." (ṣe ẹ ri i?), O n fihan ni ikẹyin ọjọ yii, bi o ṣe yẹ ki o wa.

68 Ẹ kiyesi ori kejidinlogun bayi. Kete ti a yi

orukọ naa pada tan, Ọlọrun farahan lati fi ara Rẹ han ninu ẹran-ara. Lẹyin ti a ti fi orukọ naa han - ẹniti O jẹ - Ọlọrun farahan ninu ẹran-ara. Abrahamu, ni ọsan ọjọ kan, lẹyin ọsẹ diẹ, tabi oṣu diẹ, ki a to sun Sodomu ni ina, Isaaki farahan… Ẹ kiyesi i, Abrahamu joko si abẹ igi oaku rẹ. Lọọti wa ni Sodomu, wọn si n gbadun faaji aye. Sibẹ, Oluṣọ-aguntan ni Lọọti - boya o tilẹ ni ijọ kan ti o dara nibẹ. Ohun yoowu ti o ṣe, Bibeli wipe iwa ipa ati ẹṣẹ akoko naa ba ọkan ododo rẹ jẹ. Nitorinaa, o nilati ni … gẹgẹbi ọpọlọpọ awọn Lọọti lode oni. Ṣugbọn o mọ wipe oun ko lee sọ ohunkohun nipa rẹ. Ẹ kiyesi i, o wa nibẹ.

69 Ṣugbọn Abrahamu, lẹyin ti a ti fihan fun-un - wipe Ẹlohiimu ni ẹniti o ti n ba a sọrọ - o wa joko si abẹ igi oaku, awọn ọkunrin mẹta kan si de, wọn n rin bi eniyan. Ẹ kiyesi ipa ti ifihan naa ni (ti ẹniti Ọlọrun jẹ) lara Abrahamu - ohun ti o ṣe si i. Lẹyin ti a yi orukọ rẹ pada lati Abramu si Abrahamu, o ri awọn ọkunrin mẹta ti wọn n bọ. O si pe awọn mẹtẹẹta ni ẹyọkan - "Oluwa mi" - ẹyọkan ni awọn mẹtẹẹta. Ko ri bẹẹ pẹlu nọmba kẹfa - Lọọti. O ri awọn meji ti wọn n bọ, o si ni, "ẹyin oluwa mi." Iṣipaya ati ifihan Abrahamu fi han-an wipe Oun ni ẹniti o danikan to fun ohun gbogbo, Ẹlohiimu. Iru-ọmọ rẹ si n gba nkan kannaa.

Ẹ kiyesi bi O ṣe fi ara Rẹ han, bi O ṣe fi ara Rẹ han boya o tọna tabi bẹẹkọ. Ẹ kiyesi ami ti O fihan awọn ti o gbagbọ nitootọ, kini o ṣe … O jẹ ki o mọ wipe Ẹlohiimu niyẹn. Ni bayi, o wipe, "Oluwa mi." Lẹta nla ni, O-l-u-w-a. Gbogbo ẹyin ọmọwe, ẹ mọ bẹẹ. Gbogbo ọmọwe ni o mọ wipe Ẹlohiimu niyẹn, ẹniti o danikan to funra Rẹ, Ẹlohiimu.

Ọkunrin kan sọ fun mi ni igba kan wipe, "O ko gbagbọ wipe Ọlọrun niyẹn!"

70 Mo ni, "Dajudaju, mo gbagbọ. Abrahamu sọ pe Ọlọrun ni. O ba a sọrọ, o yẹ ki o mọ̀."

O ni, “Ah, o fẹ sọ wipe Ọlọrun duro sibẹyẹn, O n jẹ ẹran maaluu, O si n mu wara maaluu, O si n jẹ burẹdi ti a fi agbado ṣe nibẹ, tabi ohun yoowu ti ẹ fẹ pe e?”

Mo ni, “O ṣe bẹẹ.” Ki lo ṣẹlẹ, o ko mọ Ọlọrun wa ni. Kini, O lee… O kan na ọwọ… Awọn eroja mẹrindinlogun ni a fi da wa: epo rọ̀bì, imọle iṣẹda, káún, yangí, ati bẹẹ bẹẹ lọ - awọn eroja mẹrindinlogun. O kan ko gbogbo rẹ papọ ni, O si mi si i, O si rin wa sori ilẹ aye. Inu mi dun pupọ wipe iru baba bẹyẹn ni. Bi idin tilẹ jẹ ara yii, sibẹ Oun yoo pe ọ. O ṣe ileri lati ṣe bẹẹ. Oun ni Ẹlohiimu.

O tun ko ẹkunwọ miiran, o ni, “Wa nihin, Iwọ [tabi ohun yoowu ti o jẹ - angẹli naa]. Sọkalẹ wa, ẹ jẹ ki a lọ wo Sodomu, ki a ri ohun ti o n ṣẹlẹ.”

71 Abrahamu, lẹyin ifihan naa, o ri i, o si mọ wipe Ọlọrun kanṣoṣo ni o wà. O ri i, o si wipe, “Oluwa mi, wọle wa. Joko. Jẹ ki n wẹ ẹsẹ rẹ.” Ko sọ wipe, “oluwa.” Ẹ kiyesi i, lẹta nla ni. Ẹnikẹni mọ iyẹn. Mo ni iwe Emphatic Diaglott. Lẹta nla ni, O-l-u-w-a; Oluwa, Ẹlohiimu, ẹniti o danikan to funra Rẹ. O ni, “Jẹ ki n bu omi diẹ, ki n wẹ ẹsẹ Rẹ, ki n si fun Ọ ni okele ounjẹ diẹ. Lẹyinnaa, O lee maa ba ọna Rẹ lọ.”

72 Ẹ wo o, mọ ti n pẹ ju nibi yii. O san ki n yara. Mo fẹ de ibi yii, n ko si mọ boya n o lee ṣe e. Ẹ farada a fun mi fun iṣẹju diẹ si i, ṣe ẹ o ṣe bẹẹ?

73 Ẹ kiyesi i - Ẹlohiimu, ẹniti o danikan to funra Rẹ, Ọlọrun. O wipe… Ẹ kiyesi ohun ti o ṣe. Awọn meji ninu wọn n wo Sodomu. O si wipe, “Ṣe o ro wipe n o fi nkan yii pamọ fun Abrahamu?” Kii ṣe ohunkohun bikoṣe ki O kọkọ fihan fun awọn wolii Rẹ, ṣe ẹ ri i. O maa n jẹ ki wọn mọ ọ. O wipe, “Emi ki yoo fi eyi pamọ, niwọn bi oun ti jẹ ẹni ibukun Ọlọrun. Oun ni yoo jogun aye, ati bẹẹ bẹẹ lọ. Iru-ọmọ rẹ yoo … [iyẹn ni wipe, oun yoo jẹ baba orilẹ-ede pupọ]… Emi ki yoo fi pamọ fun-un. Emi yoo jẹ ki o mọ.

Nitorinaa, O wipe (O bẹrẹ si fihan fun-un),

74 O wipe, “Abrahamu [ki iṣe Abramu], nibo ni iyawo rẹ S-a-r-a-h wa?” Bawo ni o ṣe mọ iyẹn? Eeṣe, ni ọjọ kan ṣaaju iyẹn, Abramu ni. Ọjọ kan tabi meji ṣaaju iyẹn, oun n jẹ Sarai; bayi, o ti di Sarah, oun naa si di Abrahamu. O ni, “Abrahamu, nibo ni iyawo rẹ, Sarah wa?”

Abrahamu wipe, “O wa ninu agọ lẹyin Rẹ.”

O ni, “Emi yoo bẹ yin wo gẹgẹbi akoko iye, ọmọ ti a ṣe ileri yii ti ṣetan lati farahan bayi. Ẹ o bi ọmọ naa.”

Sarah si rẹrin sinu ara rẹ. O ni, “Emi ti mo ti di arugbo, ki n tun ni ayọ pẹlu oluwa mi? Ti oun naa ti di arugbo? [iru nkan bẹyẹn, ṣe e mọ, nitoriti oun ti di ọmọ aadọrun ọdun, ọkọ rẹ si ti di ọgọrun ọdun, nitorinaa…] Ṣe mo tun lee ṣe iyẹn bayi?”

75 Angẹli ojiṣẹ naa, Ọlọrun ninu ẹran-ara eniyan, wipe, “Eeṣe ti o fi rẹrin?” Ifidimulẹ niyẹn. Eeṣe? O fihan wipe ifihan naa jẹ otitọ. O fihan wipe ohun ti o pe e - Ẹlohiimu - jẹ otitọ, nitori Oun ni Ọrọ naa. Iyẹn ni Heberu ori kẹrin, ẹsẹ ikejila. O ni, “Ọrọ Ọlọrun mu ju idakida oloju meji lọ, o si n pin ọkan ati ẹmi niya.” Nigbati Abrahamu ri eleyi, o da a loju nigbanaa wipe oun lee pe e ni Ẹlohiimu. Ẹlohiimu - Oun ni Ọrọ naa, ọkannaa lana, loni, ati titi lae.

76 Ẹ kiyesi i, nigbati Jesu, ti iṣe iru-ọmọ alade Abrahamu, farahan, O fi ara Rẹ han fun iru-ọmọ Abrahamu nipa ti ara ninu ami kannaa, wọn pe e ni Beelsebuubu. O fọ wọn loju - awọn alaigbagbọ - o fọ wọn loju, o si mu ki wọn sọrọ odi si I, o si ran wọn lọ si ọrun apaadi. Ṣugbọn o fi iriran ainipẹkun fun awọn onigbagbọ ti a yan si iye ainipẹkun.

Ẹ kiyesi i. Jesu ṣe ileri wipe ni ikẹyin ọjọ, ṣaaju ki Ọmọ eniyan to de, wipe Oun yoo wa lati fi ara Oun han. Ni ọjọ ti a ba n fi Ọmọ eniyan han, iru-ọmọ alade Abrahamu yoo ri ami kannaa. Ẹ kiyesi i bayi. Nigbati o sọ nibẹyẹn, ni Luuku 17:28 de 30, “Gẹgẹbi o ti ri ni ọjọ Sodomu…” Jesu ni o sọ eyi. Emi kọ ni o sọ ọ. Ojuṣe temi ni lati sọ ọ jade - lati sọ ohun ti O ti sọ, ṣugbọn Jesu ni o sọ eyi. “Gẹgẹbi o ti ri ni ọjọ Sodomu, bẹẹni yoo ri ni igba bibọ naa, ni igba bibọ Ọmọ eniyan.” Ẹ kiyesi i bayi. Ni ọjọ ti a ba n fi Ọmọ eniyan han, nigbati a ba n fi Ọmọ eniyan han fun ijọ Rẹ,

77 bii fun Abrahamu… Oun ni Ọlọrun, O n sọkalẹ wa, O fidi majẹmu naa mulẹ, o mọ ẹniti O jẹ, orukọ rẹ si yipada. Ẹ kiyesi i, o yipada ki o to de ori oke ibiti o ti wo Sodomu, ni kete ki ọmọ ileri naa to de.

Jesu sọ pe nkan kannaa… Jesu n ka Bibeli kannaa ti mo n ka, ti iwọ naa n ka. Ti o ba fẹ mọ ohun ti o jẹ, pada lọ wo ohun ti wọn n ṣe ni ọjọ Sodomu. Ẹ kiyesi i, kii ṣe ọjọ Noah o - O sọ nipa iwa aimọ wọn, bi wọn ṣe n jẹ, ti wọn n mu, ti wọn n fẹ iyawo, ti wọn si n fi iyawo fun ni - ṣugbọn ni Sodomu. Ni bayi, ko si omi mọ - Ọlọrun ṣe ileri iyẹn nipa ami oṣumare.

O fun wa ni ami kan. O maa n funni ni ami nigbagbogbo. O maa n ranti awọn ami Rẹ, O maa n jẹ

olootọ si i ni gbogbo ọdun. Ko kuna lati funni ni ami oṣumare yẹn ri. O maa n funni ni ami Rẹ. Ẹ kiyesi i, ninu ami yẹn, O ṣe ileri wipe Oun ki yoo fi omi pa aye rẹ mọ; ṣugbọn O sọ wipe yoo jona. Ẹ si kiyesi i nibi yii wipe Jesu sọ pe bi o ti ri ni ọjọ Sodomu, a o pa aye Keferi run. [Ibi yii ṣofo lori fanran.] Ẹ wo ohun ti o wa laarin wọn: ọkunrin kan, G-r-a-h-a-m, ti o n ba wọn wi - awọn oloṣelu wọnyẹn, ati ijọ ara.

Fun ijọ ẹmi,

78 oriṣi ẹgbẹ eniyan mẹta ni o wa. Iyẹn ni onigbagbọ, alaigbagbọ, ati awọn alafẹnujẹ onigbagbọ. Wọn maa n wa laarin gbogbo awọn ipejọpọ. Ti ẹ ba mọ irinmọlẹ ti o n ṣẹlẹ si mi ni, ẹ o mọ wipe wọn wa nihin ni aṣalẹ yii. Nitorinaa, o (awọn mẹtẹẹta)… Ẹ kiyesi i, bi o ṣe ri niyẹn. Awọn ẹgbẹ mẹtẹẹta yẹn wa kaakiri nibigbogbo.

79 Ti ẹ ba lee ri iyẹn, o nilati ri bakannaa nigbati a o ba fi Ọmọ eniyan han fun iru-ọmọ alade Abrahamu nipasẹ Kristi - Kristi ni iru-ọmọ alade naa - nigbati a ba n fi Oun han ni ikẹyin ọjọ.

Aye wa ni ipo kannaa bayi … nitori oorun ti o la ni ila-oorun naa ni o wọ ni iwọ-oorun. Ọjọ ikuuku ni - wọn da ẹgbẹ eniyan silẹ, ati awọn ijọ ẹlẹkọ-adamọ. Ṣugbọn imọlẹ yoo wa ni ọwọ aṣalẹ, ni wolii Jeremiah wi. Ni ọjọ naa, nigbati oorun yẹn ba jade kuro lẹyin ikuuku awọn ijọ ẹlẹkọ-adamọ lati fi ara Rẹ han, o ni aye yoo wa ni ipo ti Sodomu wa, Ọmọ eniyan yoo si tun fi ara Rẹ han fun awọn eniyan Rẹ.

Ẹ wo bi O ṣe fihan fun iru-ọmọ Isaaki. Ẹ wo bi yoo ṣe fihan fun iru-ọmọ alade naa - iyawo, ọlọla, ayaba. Ayaba naa ni iru-ọmọ alade. Gẹgẹbi Ọlọrun ti mu orilẹ-ede kan jade lati inu orilẹ-ede miiran ni Egipti, O n mu ijọ kan jade lati inu ijọ, tabi iyawo jade lati inu ijọ - ijọ jade kuro ninu ijọ. Iru-ọmọ obinrin naa ti o ṣẹku (iyẹn awọn ti o ṣẹku), ẹkun yoo wà, ati igbe, ati ipayinkeke, nitori wọn ko ni ororo ninu fitila wọn. Nigbagbogbo ni Ẹmi Mimọ n ṣe apẹẹrẹ… Wọn wa nibẹ.

80 Ohun gbogbo ti ṣetan bayi.

Ni bayi, ẹ wo ori oke. Ni bayi, ijọ … Abrahamu, Lọọti, awọn ara Sodomu; aye, ijọ, ayanfẹ - ijọ, iyawo jade kuro ninu ijọ. A wa ni ipo yẹn ni aṣalẹ yii. Aye ti wa ni ipo naa bayi.

Idibajẹ - ohun gbogbo ti dibajẹ. O ti … mo wi fun yin, ohun gbogbo ti di alupayida. Mo wa, mo si ri ami nla kan, o ni, “Agbado Alupayida.” Kini, ko dara rara! Rara. O yẹ ki iyẹn mu ẹyin alaigbagbọ fo soke. Nigbati Ọlọrun wipe, “Jẹ ki gbogbo irugbin maa so eso iru tirẹ,” ẹ si lee ṣe adamọdi agbado, ki ẹ mu ki o di agbado ti o dun lati wo loju; ṣugbọn ẹ ko lee tun iyẹn gbin. Ko si iye ninu rẹ.

81 Bi a ti ṣe ijọ naa niyẹn. A ti mu ki o rẹwa, a ti fi awọn ohun meremere ijọ ẹlẹkọ-adamọ ṣe e lọṣọ; ṣugbọn ko si iye ninu rẹ. Ko lee mu igbe-aye Bibeli wa loni. Ko lee mu ẹri ajinde Kristi jade wa. Adamodi ni: awọn eniyan ti wọn n mura daradara gan-an, awọn ti a n san owo pupọ fun, ati awọn ijọ ẹlẹkọ-adamọ ti o tobi, ti wọn si ni ọrọ̀ - ti igba ijọ Laodikea, bẹẹ gan-an ni. “Wọn ni ọrọ, wọn ko nilo ohunkohun, wọn ko si mọ wipe àre ni awọn, ati oṣi, ati afọju, ati talaka. Wọn wa ni ihooho, wọn ko si mọ ọ.”

Ti ẹnikan ba mọ wipe oun wa ni ihooho, ẹ lee ba a sọrọ; ṣugbọn nigbati ko mọ ọ, ipo oṣi niyẹn. Ẹni ikaanu ni! Maṣe kẹgan awọn eniyan, nṣe ni ki o ṣaanu fun wọn. Njẹ ti o ba jẹ iwọ ni o wa ni ipo yẹn nkọ? Njẹ ti a ko ba fi Ọrọ naa han fun o nkọ? Kini iwọ yoo ṣe? Kini o tun ṣe pataki, ti oju rẹ ba fọ tobẹẹ ti o ko lee ri i? Ipo oṣi niyẹn.

O ti wa ni ipo naa gan-an - o ko lee fi ọwọ kan-an. O wa nibẹ. Ohun ti O sọ wipe yoo ṣẹlẹ niyẹn - awọn ami wọnyi yoo wa ni ikẹyin ọjọ. Ṣe ẹ ri ibiti wọn wà, bẹẹ gan-an ni.

82 Ẹ kiyesi i bayi. Adamọdi - ṣe ẹ mọ, bi ohunkohun… Bii ki a mu kẹtẹkẹtẹ, ki a da a pọ mọ ẹṣin, akọ ẹṣin, kini ẹ o mu jade lati ibẹ? Ẹ o ri ibakasiẹ. Ṣugbọn ibakasiẹ yẹn ko lee tun ara rẹ bi mọ. Ṣe ẹ ri i, Ọlọrun sọ pe, “Jẹ ki gbogbo irugbin maa so eso iru tirẹ.” Ibo wa ni ẹkọ wipe ẹranko di eniyan ti wá bayi? Iṣẹ ọwọ yin ti ṣe idalẹbi fun ohun ti ẹ sọ wipe ẹ gbagbọ. Ọlọrun wipe, jẹ ki gbogbo irugbin maa so eso iru tirẹ. Ko lee tun ara rẹ bi pada mọ. Rara, rara, o ti tan.

Mo si ro wipe ibakasiẹ jẹ ọkan ninu awọn alaimọkan ti o ga julọ ti mo tii ri ri. O ko lee kọ ọ ni ohunkohun. Yoo joko sibẹ, pẹlu awọn eti nla ti o gun wọnyẹn, ṣe ẹ mọ, yoo duro di igba ti o kẹyin lati ta ọ ni ipa, ki o to ku. O kan … o ko lee kọ ọ ni ohunkohun. Iyẹn ran mi leti … o lee joko sibẹ, ki o maa sọ awọn nkan fun-un. Iyẹn ran mi leti awọn eniyan kan, ti wọn sọ wipe awọn jẹ onigbagbọ loni, wọn ni eti ti o tobi, ti o si gun. Wọn yoo ni, “Ọjọ iṣẹ-iyanu ti kọja, hain, hain, hain.” Ko mọ ibiti o ti wá. Ko mọ ohunkohun nipa rẹ. Kiki ohun ti o mọ ni ẹkọ ijọ kan.

83 Ṣugbọn ẹ jẹ ki n sọ fun yin, mo bọwọ fun ojulowo. Ọmọ, o lee sọ fun ọ wipe ojulowo ni oun. O lee sọ ẹniti baba rẹ jẹ fun ọ, ati ẹniti iya rẹ jẹ, ẹniti iya-iya rẹ jẹ, ẹniti baba-baba rẹ jẹ. Ojulowo ni. Bẹẹ naa ni ojulowo Kristẹni. Ẹ lee tọpinpin rẹ pada sinu iwe Iṣe Awọn Aposteli, ki ẹ ri ibiti wọn ti wá - ojulowo Kristẹni, ti a fi Ẹmi

kannaa bi, nkan kannaa, yoo maa huwa bakannaa, pẹlu awọn oninunibini kannaa. Awọn kẹtẹkẹtẹ ati ẹṣin n jẹ̀ papọ - bẹẹ ni. Bi o ṣe ri niyẹn. Ẹ nilati ni i. Ọjọ alupayida ni a wa yii.

84 Mo ri akọsilẹ kan ninu iwe “Reader's Digest” laipẹ yii. Wipe ti wọn ba n fi ounjẹ alupayida yii bọ awọn obinrin, wọn ko ni lee bimọ. Wọn n yipada. Wọn n tobi si i ni ejika, wọn si n tinrin si i nibi itan. Eeṣe? Ẹ mọ wipe eniyan maa n pa ara rẹ run nipa ọlaju. Ẹ pada sọdọ Ọlọrun! Ẹ gba Ọlọrun gbọ! Ẹ pada si ojulowo irugbin. Ẹ pada wa, ki ẹ gba a gbọ.

Ẹ ti ka awọn fanran mi - ẹ ni awọn fanran mi ni mo fẹ sọ - mo ro wipe mo gbọ wọn, ani iwaasu nipa ojulowo irugbin, ati igi iyawo, ati awọn nkan wọnyẹn, ti o jẹ otitọ. Oluwa mọ bẹẹ. Bi a ti sọ asọtẹlẹ awọn nkan wọnyẹn ni ọpọlọpọ ọsu sẹyin… Ẹyin eniyan, ohun ti ẹ n ri nibi yii … kekere ni ẹ n ri ti o n ṣẹlẹ yii. Ẹ beere lọwọ awọn eniyan ti o ti wa nibẹ tẹlẹ. Ẹ beere boya o kuna ni igba kan ri. O n sọ nipa awọn eniyan, ilẹ riri, ati awọn nkan ti yoo ṣẹlẹ - Ẹmi Mimọ maa n sọ fun wa. Ṣe bẹẹ ni? Awọn ọkunrin wa nibi yii ti wọn ti… Dajudaju.

Ati oniruuru awọn eniyan

85 bii Marilyn Monroe, ṣaaju ki o to … ku. Wọn sọ wipe o pa ara rẹ ni. Ko pa ara rẹ. Aisan ọkan ni o pa a. Dajudaju. Ọkunrin yii, jagunjagun yii, ni Maginot Line ni Germany, gbogbo awọn nkan wọnni - ẹgbẹẹgbẹrun awọn nkan ni o ṣẹlẹ bẹẹ gẹlẹ ni gbogbo igba! Ko lee jẹ ohunkohun bikoṣe Ẹmi Mimọ.

O ṣe ileri rẹ. O sọ awọn nkan meje ni 1933, awọn nkan ti yoo ṣẹlẹ, gbogbo wọn ni o si ti ṣe, ayafi meji. O pe gan-an ni. Ati bi Aarẹ Kennedy yoo ṣe wọle - gbogbo rẹ wa ninu iwe mi nibi bayi. Eyiti a sọ ni ọdun mẹtalelọgbọn sẹyin. Bẹẹ ni. Bi wọn yoo ṣe kọ ibi isadi Maginot Line, ni ọdun mọkanla ṣaaju ki wọn to kọ ọ; ati bi Hitler yoo ṣe dide, ati ijọba Afipajọba (Fascism), ati ijọba Gbogbogboo (Nazism); ati bi gbogbo rẹ yoo ṣe pari sinu ijọba Aparo-kan-ko-ga-ju-ọkan-lọ (Communism), ati bi ijọba Aparo-kan-ko-ga-ju-ọkan-lo (Communism) yoo ṣe pa Katoliiki run - yoo ṣe bẹẹ, ohun yoowu ti wọn ṣe.

O fihan wipe igbimọ ẹsin agbaye kan yoo wà, ati bi gbogbo awọn ijọ yoo ṣe parapọ, ti wọn yoo si di “aworan ẹranko naa.” Ẹ ri i wipe wọn ti wà lọna ati ṣe bẹẹ bayi. Bẹẹ gan-an ni. O nilati ṣẹlẹ, nitori ko kuna ri lati… Ẹnikẹni ti o ba mọ iyẹn - ẹnikẹni, wo wọn kaakiri agbaye - ko fi igba kankan kuna ri. Ni ọpọlọpọ ọsu ati ọdun ki o to ṣẹlẹ, o si maa n ri bẹẹ gẹlẹ. Ọlọrun niyẹn laarin yin, ẹyin eniyan - Ọlọrun ninu wa, Ẹmi Mimọ.

Ẹ kiyesi i, Jesu wipe a o mọ iru-ọmọ alade naa nipa nkan kannaa, ni Luuku ori kẹtadinlogun. Ah, “Ẹ pada, ẹyin aṣako,” kuro ninu ijọ ẹlẹkọ-adamọ sinu tiyin.

86 Ẹnikẹni ninu wa lee gbagbọ wipe Ọlọrun… Ti o ba gba Ọlọrun gbọ, o mọ wipe Ọlọrun n mu alaisan lara da. Iyẹn ko ni ariyanjiyan ninu. Ṣugbọn ti o ko ba gba iyẹn gbọ, o ko… Wọn sọ ni igba yẹn wipe, “Ah, a mọ wipe O lee wosan; ṣugbọn ko lee gbala.”

Ṣugbọn loni, wọn ni, “O lee gbala; ṣugbọn ko lee wosan,” ṣe ẹ ri i. Eṣu kannaa ni, nkan kannaa ni; Oun ni Olugbala ati Oluwosan. Oun ni Jehofa-jire ati Jehofa-rafa. Ah, ẹ pada! Ẹ ranti, O ṣe ileri bi ohun gbogbo ṣe ri bayi, ati ohun ti yoo ṣẹlẹ. O sọ wipe yoo ṣẹlẹ, o si nilati ṣẹlẹ.

87 Ẹyin ara, mo tọrọ aforiji. Mo ti da yin duro pẹ. Ẹ jẹ ki a tẹriba fun iṣẹju kan. Emi yoo… Emi yoo pari eyi, boya ni alẹ ọla. Mo si ni bii oju ewe mẹfa si i lori rẹ. Ẹ tẹriba fun iṣẹju kan. Ẹ wa ni tọwọtọwọ, gbogbo yin.

O lee ṣai gba pẹlu mi. O ni ẹtọ lati ṣe bẹẹ. Emi naa ni ẹtọ lati sọ ohun ti mo ro. Mo ni Iwe Mimọ. Ko si ohun ti mo lee sọ, ti Ọlọrun ko ba ti i lẹyin, a jẹ wipe Urimu ati Tumimu naa ko ṣiṣẹ niyẹn. A o si kọ̀ ọ́. Ko si bi o ti wu ki o dara loju to, bi o ṣe dabi ojulowo to, Urimu ati Tumimu nilati fi i han. Irugbin naa nilati hu. Ti ko ba ṣe bẹẹ, a jẹ wipe ko ri bẹẹ.

88 Fun iwosan bayi - mo ti gbiyanju lati sọ fun yin wipe emi kii ṣe Oluwosan. Ọpọlọpọ awọn eniyan ni wọn n pe ara wọn ni Oluwosan. Ọpọlọpọ awọn alatako naa wa pẹlu, ti wọn n pe awọn eniyan ni Oluwosan, wipe … lati ṣe atako wọn ni. Ọkan wọn ko tọ pẹlu Ọlọrun, ṣe ẹ ri i. Ẹnikẹni mọ wipe ko si ẹnikan ti o lee wo ẹnikan san. Ọlọrun ni o n wo aisan. Jẹ ki Ọlọrun pe fun iku rẹ; o lee gba gbogbo adura, ki awọn ile-iwosan si maa fun o ni abẹrẹ lojoojumo, iwọ yoo ku bakannaa ni.

89 Ti mo ba ge ọwọ mi ni aṣalẹ yii, ti mo duro sibi yii pẹlu ọwọ gige, ko si oogun kan ni aye yii ti o lee wọ ọwọ mi san. A ko ni oogun ti o lee wosan. Eyikeyi oniṣegun yoo sọ bẹẹ fun ọ. Yoo kan mu ki oju ọgbẹ naa mọ́ ni, ṣugbọn Ọlọrun ni o n wosan. Ko lee dá ẹran ara.

Ti mo ba ge ọwọ mi, ti o si wipe, “Ah, Arakunrin Branham, oogun kan wa ti yoo wo iyẹn san.” Ko buru, mo fẹ mọ ohun ti o jẹ. Ẹ jẹ ki n fi han yin. Ti mo ba ge ọwọ mi, ti mo si ṣubu lulẹ, ti mo ku si ibi yii, dokita kan lee wa, ki o fi oogun si ara kiku mi, ki o si mu ki ara mi wa bakannaa fun aadọta ọdun; ki o ran ọwọ mi papọ, ki o si maa fun mi ni abẹrẹ ti n mu egbo jinna ni ojoojumọ. Ni aadọta ọdun si akoko yii, oju egbo yẹn yoo ri bi

o ṣe ri lakọkọ ni. Ti oogun ba lee wosan ọgbẹ san ni, kini ṣe ti ko wo iyẹn san? Oogun yoowu ti o ba lee wo ọgbẹ ọwọ mi san, yoo wo ọgbẹ ara tabili naa san, yoo wo ọgbẹ ara aṣọ mi san. Ti o ba lee wo ọgbẹ kan san, yoo wo ọgbẹ miiran san, laibikita ibi ti o wà.

O lee wipe, "O dara, eniyan ni a ṣe oogun fun." Eeṣe ti ko fi wosan nigbanaa? Iwọ yoo wipe, "O dara, iye ti kuro ninu rẹ ni."

A jẹ wipe nkan miiran wa ti n wo ni san, yatọ si oogun. Iye ni. Dajudaju, Ọlọrun ni iye. O daju wipe Oun ni. Sibẹ, awọn ẹlẹṣẹ kan ti ba a jẹ, ṣugbọn sibẹ, o wa ni aworan Ọlọrun; iye ti o ni, Ọlọrun ni o fi fun ọ. Iwọ naa mọ bẹẹ. Bẹẹkọ, nitori Ọlọrun ni Oluwosan. Iye ni Oluwosan. Ẹ gba iyẹn gbọ. Mo ti ri i ti a ṣe ọpọlọpọ nkan.

90 Iwọ ṣaa gba a, o ki yoo ha ṣe bẹẹ bi?

Ki a to ṣe iyẹn, ẹni melo ni o ni idaniloju nibi yii? Ṣaaju… Ti o ba jẹ oju titun nibi, ti o ko wa si ibi ri, ṣugbọn o gbagbọ wipe Oun ni Ọmọ Ọlọrun; ati nipa eyi (iwaasu aṣalẹ oni, Ọrọ yẹn nikan, ki O tilẹ to ṣe ohunkohun), wipe o gba a gbọ, o si fẹ ki n ranti rẹ ninu adura, na ọwọ rẹ soke, ṣe iwọ yoo ṣe bẹẹ? Ki Ọlọrun bukun fun yin. Akiika - ọwọ bii ọọdunrun tabi irinwo. Ki Ọlọrun bukun fun yin. Igbagbọ maa n wa nipa gbigbọ, gbigbọ Ọrọ naa. Idi ti mo fi sọ iyẹn ni lati ri … lati ri ojurere niwaju Ọlọrun. Mo ro wipe dipo ki n pe ila adura wa si oke nibi, emi yoo kuku jẹ ki ẹyin gbadura.

91 Ẹ jẹ ki n fun yin ni ẹsẹ Iwe Mimọ kan na. Ohun ti a ba n ṣe nilati ba Iwe Mimọ mu! O nilati ba Iwe Mimọ mu. Ọlọrun ki yoo bu ọla fun ohunkohun miiran. Ọlọrun ki yoo bu ọla fun irọ. Ẹ mọ bẹẹ. O ko lee ka iyẹn si i lọrun. Kii bu ọla fun irọ; Ọrọ Rẹ nikan ni O maa n bu ọla fun. Ṣugbọn O ṣe ileri wipe "Ọrọ mi ki yoo pada sọdọ mi lofo. Yoo ṣe ohun ti a ran-an." A si ri i wipe a pin Ọrọ naa fun ọjọ oni. Ko si bi aigbagbọ ṣe pọ ni ibudo to, Ọlọrun yoo bu ọla fun Ọrọ Rẹ nigbati o bạ ri igbagbọ lati fi bu ọla fun-un.

92 Nibikan ninu ile yii, mo fẹ ki ẹ gba ẹsẹ Iwe Mimọ yii: Heberu, ori kẹta ni mo gbagbọ wipe o wà. Bibeli wipe Oun ni olori alufaa nisisiyi, eyiti o mọ ailera wa. Iwọ ti o na ọwọ rẹ soke, mo fẹ ki iwọ, ni kete ti isin ba ti pari, mo fẹ ki o wa sibi yii, ki a si gbadura fun ọ; ki o gba Kristi gẹgẹbi Olugbala rẹ, ki o si lọ si ọkan ninu awọn ijọ ti o wa ni agbegbe ibi yii, ibi yoowu ti ó wa, nibiti wọn ti n waasu ihinrere. Tọ wọn lọ ki o si beere fun baptisiimu Kristẹni; oluṣọ-aguntan yoo ran ọ lọwọ lati ibẹ lọ. Eniyan Ọlọrun ni. A pe e lati jẹ eniyan Ọlọrun. Yoo maa tọ ọ lati ibẹ lọ. Ṣaa… Ti mo ba n gbe ilu yii, emi yoo darapọ mọ ọkan ninu awọn ijọ ti o wa nibi yii. Emi yoo tọ wọn wa - awọn ti wọn gba ihinrere gbọ. Emi yoo wa nibẹ. Dajudaju. Emi yoo fi ara mọ wọn, nitori ohun ti o nilo lati ṣe niyẹn. Ohun ti o nilati ṣe niyẹn.

93 Ti Oun ba jẹ olori alufaa ti o lee mọ ailera wa nipa mimọ ohun ti a n la kọja bayi, ọkannaa ni Oun lana, loni, ati titi lae. Nitorinaa, O nilati ṣe bi o ti ṣe ni ana. Ẹ kiyesi i. Obinrin kekere kan fi ọwọ kan aṣọ rẹ ni igba kan, O si yiju pada, O mọ ohun ti o ni, O si sọ fun-un wipe igbagbọ rẹ ti gba a la. O si mọ ninu ara rẹ… Ko ṣe wahala lati fidi rẹ mulẹ. Ko nilo lati fidi rẹ mulẹ. O ko nilati fidi ohunkohun mulẹ; o nilati gba Ọlọrun gbọ ni. O ko nilati wadi Ọlọrun rara. O ko lee wadi boya Ọlọrun wà, lati gba ẹmi rẹ la. Ki o kan jade sita, ki o si wipe, "Jẹ ki n ri Oun." O nilati gbagbọ ni.

94 Gbogbo ohun ija Ọlọrun jẹ iyanu: ifẹ, ayọ, igbagbọ, ifarada, suuru, iwa tutu - iyanu ni gbogbo rẹ. A maa n wo awọn ohun ti a ko lee ri pẹlu oju wa ti ara. Kristi n bẹ nihin ni aṣalẹ yii. O ṣe ileri wipe, "Ibiti ẹni meji tabi mẹta ba pejọ pọ si ni orukọ mi, emi wa laarin wọn." ("Emi wa nibẹ." "Emi" lẹẹkan si i.) O wa nihin.

Ọkannaa ni lana, loni, ati titi lae. Iwọ gbadura,

ki o wipe, "Jesu Oluwa, aisan n ṣe mi [tabi ohunkohun ti o ṣe alaini]. Mo ṣe alaini, mo si fẹ ki iwọ, Ọlọrun ọwọn, ṣaanu fun mi, ki o wo mi san, ki o mu mi larada. Ti mo ba ni igbagbọ ti o to, Oluwa, lati fi ọwọ kan Ọ… Mo mọ wipe Arakunrin Branham ko mọ mi. Ajeji ni mi, mo si mọ wipe ko mọ mi.

"Njẹ ti ọkunrin naa ba ti sọ otitọ fun mi (eyiti mo gbagbọ wipe bẹẹ ni o ri, nitori inu Ọrọ Rẹ ni o ti wa - mo ti ka a. Mo ri i wipe o pe.), fidi rẹ mulẹ bayi. Mo gba wipe iru-ọmọ Abrahamu ni mi nipasẹ Kristi. Mo gba wipe iru-ọmọ alade ni mi, ti o gbagbọ ninu Jesu Kristi, ti iṣe iru-ọmọ alade naa. Mo gbagbọ wipe ara iyawo Rẹ ni mi, ijọ Rẹ ti O n bọ wa fun. Aisan n ṣe mi, mo si ṣe alaini. Jesu Oluwa jọwọ jẹ ki n fi ọwọ kan aṣọ Rẹ. Ki o si fidi rẹ mulẹ fun mi nipa biba mi sọrọ nipasẹ Arakunrin Branham, gẹgẹbi o ti ṣe ileri wipe yoo ri, gẹgẹbi o ti ri ni ọjọ Sodomu. Jẹ ki (emi), jẹ ki o sọ ohun ti mo n ro fun mi, ti mo n gbadura fun, ohun ti mo fẹ, ohun ti aini mi jẹ, ani nkankan nipa mi." Iwọ ṣe bẹẹ. Ṣaa ṣe bẹẹ.

95 Baba wa ọrun, gbogbo rẹ wa lọwọ Rẹ bayi. Gbogbo ohun ti mo lee ṣe niyi, tabi ẹnikẹni - kiki ki n sọ ohun ti O ti sọ nibi yii ni, ti iṣe otitọ. Fidi rẹ mulẹ bayi, Oluwa, wipe otitọ ni. Mo ti sọrọ nipa Rẹ; sọrọ wipe otitọ ni mo sọ. Ni orukọ Jesu Kristi, Amin.

96 Mo fẹ ki o gbagbọ, ṣaa ni igbagbọ. Ki ẹnikẹni maṣe maa rin kiri. Ẹ joko tọwọtọwọ. Mo fẹ ki o fi oju inu wo o wipe Kristi duro niwaju rẹ - O jinde kuro ninu oku, O gba inu ogiri wọle ni igba kan, O jẹ ounjẹ, O ni, "Fi ọwọ kan mi. Mo jẹ́ eran-ara ati egungun," O si parẹ mọ wọn loju. O ṣe ileri wipe Oun yoo farahan ni ikẹyin ọjọ ninu ẹran-ara eniyan lẹẹkan si i - ninu ẹran-ara rẹ - gẹgẹbi O ti ṣe ni ọjọ Sodomu. Ọlọrun, ti iṣe Kristi (ti o farahan ninu ẹran-ara), wa ninu ijọ Rẹ̀ bayi, iyawo Rẹ̀. Wọn ti n di ọkannaa. Akoko isọkan ni a wa yii: awọn ijọ n parapọ sọkan, awọn orilẹ-ede n parapọ sọkan, iyawo ati Kristi naa n parapo sọkan, ṣe ẹ ri i. Akoko isọkan niyi.

97 Iwọ ṣaa gbagbọ.

Ṣe o rọrun? Maṣe gbiyanju lati daamu, tabi lati tẹ ohunkohun, nitori o ki yoo ri nkankan gba. Ṣaa sọ pẹlu irẹlẹ wipe, "Oluwa, mo gbagbọ." Ki ẹnikan ṣe bẹẹ.

Ni bayi, mo… Ẹni melo ni o joko niwaju mi, paapaa julọ… Mo mọ awọn ọkunrin ti o wa nibi yii, ati awọn ti o wa nibi yii. Mo mọ awọn kan ti o joko sibi yii. Ibi yii nkọ, niwaju mi taara? Ẹ jẹ ki a pa ọkan pọ sara ẹgbẹ kekere ti o wa nibi yii. Ẹni melo ni koi tii ri i ki Kristi fi ara Rẹ han bẹyẹn? Ẹ jẹ ki a ri ọwọ yin, ẹniti ko ri i ri. O dabi ẹni wipe gbogbo eniyan ni o ti ri i. O dara. Ẹ gbadura bayi. Ẹ farabalẹ. Emi ko mọ boya yoo ṣe e. Emi ko lee sọ bẹẹ. Ọwọ Rẹ̀ ni o wà. Ṣe yoo jẹ ki igbagbọ yin lagbara? Oluwa ti gbọ iyẹn. O mọ ohun gbogbo.

98 Ọkunrin ti o joko sibẹyẹn, eyiti ìpákè n da laamu - ṣe o gbagbọ wipe Ọlọrun yoo wo aisan ìpákè yẹn san? O gbagbọ? Ajeji ni a jẹ si ara wa, bi mo ṣe ro - iwọ ati emi? Emi ko mọ ọ. Emi ko ri ọ ri. Ṣugbọn ohun ti o n gbadura nipa rẹ niyẹn. Na ọwọ rẹ soke, ti o ba ri bẹẹ. Na a soke.

Ṣe ẹ gba iyẹn gbọ … ṣe ẹ gbagbọ wipe nigbati Anderu sọ fun Simoni wipe ki o wa wo o, wipe awọn ti ri Messiah, nigbati o si de iwaju Jesu Oluwa (nitoripe o ti fi ọwọ kan nkankan bayi, ani adura rẹ) O sọ ẹniti o jẹ fun-un. Ṣe o gbagbọ wipe Ọlọrun lee sọ ẹniti o jẹ fun mi? Ti o ba gba a gbọ, O lee ṣe e. Ṣe iyẹn yoo mu ọ lọkan le lati gbagbọ pẹlu gbogbo ọkan rẹ? Ṣe yoo ṣe bẹẹ fun ẹyin ti o ṣẹku naa?

Ọkunrin naa ti na ọwọ rẹ soke, wipe ohunkohun ti a sọ fun oun (emi ko mọ - mo nilati gbọ fanran naa, ṣe o ye yin), ohun yoowu ti o jẹ, wipe otitọ ni. Ṣe bẹẹ ni, sà? O dara. Ohun yoowu … otitọ ni. Ọgbẹni Shepherd, gbagbọ pẹlu gbogbo ọkan rẹ. Bi iwọ ba lee gbagbọ… Iyẹn dabi igba ti O wipe, "Simoni ni orukọ rẹ, ọmọ Jona." Ti o ba lee gbagbọ bayi, ohun ti o ṣe pataki niyẹn. Kini? Ó ṣe ileri rẹ̀. Oun ni o fun wa ni ileri naa. Iyẹn fihan wipe O wa nihin. Kii ṣe emi nikan; O wa ninu tirẹ naa. O wa ninu ara awọn onigbagbọ.

99 Arabinrin, ti o n sọkun, ti o si n gbadura, ti o dorikodo, ti arun jẹjẹrẹ n pọn loju - ti o ko ba bẹru, ṣugbọn ti o gbagbọ, Ọlọrun yoo mu ọ lara da, ti o ba lee gba a gbọ. O fẹ padanu rẹ, dajudaju… Iyaafin Hood, gbagbọ pẹlu gbogbo ọkan rẹ bayi, wipe Jesu Kristi ti mu ọ lara da, iwọ yoo si ri ohun ti o beere gba. Ṣe iwọ yoo gba a gbọ pẹlu gbogbo ọkan rẹ bayi? Amin.

Obinrin kan joko ni ẹgbẹ rẹ ti inu n run, pẹlu aisan ọkan, ati oriṣiriṣi aisan. Ti o ba gbagbọ pẹlu gbogbo ọkan rẹ, o lee ri iwosan rẹ gba. Ṣe o gba a gbọ pẹlu gbogbo ọkan rẹ, ki o si gba a? O ṣe bẹẹ? O dara.

Ọkunrin ti o wa nibẹyẹn pẹlu idi ti o yọ - ṣe o gbagbọ wipe Ọlọrun lee wo idi ti o yọ yẹn san ki O si mu ọ larada? Dide duro. Kini o ro nipa rẹ, iwọ ti o joko si ẹgbẹ rẹ pẹlu aisan ìpákè? Ṣe o gbagbọ wipe Ọlọrun lee wo aisan ìpákè yẹn san, ki O si mu ọ lara da? Obinrin ti o joko si ẹgbẹ rẹ nibẹyẹn ni ẹfori n ba ja. O ti lọ bayi, tabi bẹẹkọ? Ṣe o ri i, igbagbọ rẹ ni o ṣe e. Gbogbo ohun ti o nilati ṣe niyẹn - ṣaa gbagbọ.

100 Obinrin kan niyi pẹlu arun atọgbẹ. Ṣe o gbagbọ wipe Ọlọrun yoo mu ọ larada, arabinrin, ti o joko sibẹyẹn pẹlu arun atọgbẹ? Ṣe o gbagbọ wipe Ọlọrun lee sọ ẹniti o jẹ fun mi? O gbagbọ? Omidan Robinson, orukọ rẹ niyẹn. Gbe ọwọ rẹ le ọkunrin yẹn fun arun ìpákè yẹn. Boya Ọlọrun yoo mu oun naa lara da pẹlu. Ti o ba gba a gbọ, ṣe iwọ yoo ṣe bẹẹ? Ko buru, sa. Obinrin ti o joko si ẹgbẹ rẹ, gbe ọwọ rẹ le e, sà. O ni aisan ara wiwu. Ṣe o gbagbọ wipe Ọlọrun yoo wo ara wiwu yẹn san, ki O si mu ọ larada? Ti o ba gbagbọ, iwọ naa yoo ri iwosan rẹ gba pẹlu. O nilati gba a gbọ.

101 Ifidimulẹ niyẹn. Ọlọrun ni o ṣe ileri. Ẹni melo ni o gbagbọ wipe Kristi wa nihin? Ṣe ẹ gba a gbọ? Gbogbo ẹyin ti ẹ wa niwaju Rẹ bayi, ti ẹ si n fẹ aanu lati ọdọ Rẹ, ti ẹ n fẹ aanu fun ọkan yin, ti ẹ si fẹ gba a bayi, nigbati ẹ wa niwaju Rẹ, ti O si farahan…

Ẹnikan lee wa sibi yii pẹlu àpá èsó ni ọwọ rẹ̀, ati àpá ẹ̀gún, ki o wipe, "Emi ni Oluwa." Gbogbo agabagebe eniyan ni o lee ṣe bẹẹ, ṣugbọn iye… Ara Jesu Oluwa wa ni ọwọ ọtun Ọlanla bayi. Nigbati O ba de, igba ki yoo si mọ - nigbati ara yẹn ba pada sori ilẹ aye. Ṣugbọn Ẹmi Rẹ wa nihin. Iye Rẹ n fun wa ni idaniloju wipe O wa nihin, ṣe o ye yin. "Emi yoo wa pẹlu yin, ani ninu yin, titi de opin aye."

102 Iwọ ti o fẹ aanu lati ọdọ Rẹ bayi, ṣe iwọ yoo dide duro fun adura? Ni gbogbo inu ile yii, iwọ ti … ibikibi ti o ba wa, iwọ ṣaa dide duro. Ki Ọlọrun bukun fun yin ni ẹyin ibẹyẹn. Bẹẹ ni, ẹ ṣaa maa dide duro. Dide duro lori

ęsę rę, gbogbo ohun ti mo fę ki ę şe niyęn. Ę şaa dide duro fun işęju kan, lati gbadura. Ti o ba duro fun Oun… Ti o ba n tiju Rę bayi, Oun yoo tiju rę niwaju Baba. Ti o ba si … ti o ba n fę lati jęwọ Rę nisisiyi, Oun naa yoo jęwọ rę niwaju Baba.

“Mo fę gba Kristi gęgębi Olugbala mi bayi. Mo fę ki O fi Ęmi Rę kun mi bayi. Mo fę ki O…” Ę wà ni inaro fun igba dię ki a lee gbadura, ti ę ba fę. Ę dide duro. O dara. Mo fę … A dari mi lati şe bęę ni, lati ję ki… Ipe si pępę niyi. Ę dide duro. Awa ko ni pępę fun yin lati wá si; ọkan rę ni pępę. Şaa mu gbogbo aigbagbọ kuro, ki o si mọ wipe O wa nihin bayi. Dide duro lori ęsę rę, iwọ ti o fę gba Kristi bayi, ni iwaju Ọlọrun ti o mọ wipe a fihan bayi. Ę ję ki a tęriba.

103 Jesu Oluwa, tirę ni wọn. O wipe, “Ko si ęniti o lee tọ mi wa bikoşepe Baba ba fa a.” Bayi, ni ibamu pęlu imọ-ijinlę, wọn ko tilę lee na ọwọ wọn soke. Ofin işęda ti o n fa nkan wa silę sọ wipe ọwọ wa nilati wa ni isalę. Şugbọn iye wa ninu wọn, a si mu iye naa wa si itosi iye ainipękun, ani Kristi. Wọn şe ipinnu ninu ọkan wọn wipe awọn ti kọ aye silę. Wọn na ọwọ wọn soke, wọn si dide duro lori ęsę wọn, wọn tako ofin işęda ti o n fa nkan wa silę, wipe iye kan wa nibę. Bęę naa ni a tako ofin aye, ati aigbagbọ. Ni orukọ Jesu Kristi, tirę ni wọn.

Ębun ifę ihinrere ni wọn. Iranti iwaasu aşalę yii ni wọn, ati ifarahan nla Rę laarin wa. Fi orukọ wọn sinu iwe iye Ọdọ-aguntan nibęyęn. Oluwa, a gbadura wipe ọkọọkan wọn yoo wa nibę gęgębi ọmọ Rę, ani olufę Rę. Fi Ęmi Mimọ Ọlọrun kun ọkan wọn. Ję ki agbara Ọlọrun Olodumare wọ inu aye wọn, ki iręlę, ifę, işeun ati iwa pęlę lee ma ti inu wọn jade; ati itara lati ri i wipe a gba awọn ęlomiran la, awọn ti wọn wa ni ipo ti awọn naa wa nigbakan. Gba bęę, Oluwa.

Ohun kanşoşo ti a lee şe, Oluwa, ni ki a gbagbọ. Wọn dide duro gęgębi iranti igbagbọ wọn. Pęlu igbagbọ temi ati tiwọn papọ, a fi si ori pępę Rę nipa igbagbọ. Awọn ni ębọ ti o wa nibę, wọn n duro ki Ọmọ Ọlọrun ti a fi rubọ gba wọn sinu ijọba Rę. Gba bęę, Oluwa. Ki wọn ję tirę bayi, ni orukọ Jesu Kristi.

104 Ęyin ti ę gbagbọ ninu Rę pęlu gbogbo ọkan yin, ti ę dide duro, ę na ọwọ yin soke, ki ę wipe, “Mo gba a gbọ. Mo gba a nisisiyi gęgębi Olurapada mi, mo si n fę baptisiimu Ęmi Mimọ.” Ę na ọwọ yin soke. Ki Ọlọrun bukun fun yin. Ę lee joko bayi. Mo fę ki ę wa aaye lọ sinu ijọ kan, kiakia.

Ni alę ọla, a o şe ipade fun baptisiimu Ęmi Mimọ - ni alę ọla, ninu ile nibi yii. Ọpọlọpọ gbawere-męsin ni o wa ti wọn n pe ni baptisiimu Ęmi Mimọ, şugbọn iyęn ko sọ wipe ko si ojulowo Ęmi Mimọ, ojulowo Ęmi Mimọ Ọlọrun, bakannaa. Mo si gbagbọ wipe Oun yoo ba wa pade nihin ni alę ọla.

105 Ęni melo ninu ile yii ni o ni idaniloju wipe a ti wa ni igba ikęyin? Ęni melo ni o ni idaniloju wipe otitọ niyi? Wipe Ọrọ naa nilati ri bayi ni ikęyin ọjọ? Ę na ọwọ yin soke. Ęni melo ninu yin ni o ję onigbagbọ? Ę ju ọwọ yin. O dara. Jesu sọ awọn ọrọ wọnyi, “Ami wọnyi ni yoo maa ba awọn ti o gbagbọ lọ,” ti o ba ję onigbagbọ. Bayi, ęni melo ni o nilo Kristi ninu ara rę? Ę na ọwọ yin soke. O dara. Ęyin onigbagbọ ti ę joko si ęgbę wọn, ę gbe ọwọ yin le ara yin. Bi ę şe n gbadura ninu ijọ yin, bęę naa ni ę o şe gbadura nibi yii. Maşe gbadura fun ara rę. Iwọ gbadura fun wọn; awọn naa n gbadura fun ọ. Bibeli si wipe, “Wọn yoo gbe ọwọ le alaisan; ara wọn yoo si da.” Gbadura bi o şe maa n gbadura, pęlu ileri.

Jesu Oluwa, tirę ni wọn. Gba wọn sinu ijọba Rę. Wo ęnikọọkan san, awọn ti o ni aşọ-ilewọ wọnyi, ni orukọ Jesu Kristi Oluwa. Gba bęę, Oluwa. Satani ti padanu agbara rę. Ki agbara Ọlọrun Olodumare wo ęnikọọkan san.

MESSAGE hub online

www.messagehub.info

Ìwàásù lati ęnu
William Marrion Branham
"... Ati ni ọjọ́ ohùn angęli keje ..." Ifihan 10:7